# ẸKA TÓ Ń FI
# Ọ̀RỌ̀ TÓ Ń LỌ TÓ
# ÌLÚ LÉTÍ

# ÌWÉ ÀDÉHÙN ÀJỌ
# ORÍLẸ̀ - ÈDÈ

UN LIBRARY

JUL 17 1995

ÀTI

UN/SA COLLECTION

# ÌWÉ ÒFIN ILÉ - ẸJỌ́ ÌDÁJỌ́
# ÒDODO

ÀJỌ ORÍLẸ̀ - ÈDÈ ÀGBÁYÉ. NEW YORK

*Produced by the*

**United Nations Information Centre, Nigeria**

In Commemoration of the
Fiftieth Anniversary of the
Signing of the Charter of the United Nations

***Translation into Yoruba***
*by*
**Dimeji Ajikobi**

Ni 26/6/1945 ni wọ́n f'ọwọ́ síwèé àdéhùn àjọ orílẹ̀-èdè lágbàáyé ni ilu San Francisco l'ópin ìpàdé àjọ náà. Ó di àmúlò ni 24/10/1945. Lára àdéhùn náà ni òfin ilé-ẹjọ́ ìdájọ́ òdodo àgbáyé.

Àjọ gbogboògbò gba àwọn àtúnṣe àwọn kókó-àdéhùn 23, 27 àti 61 ni ìpàdé tí wọn ṣe ni 17/12/1963. Ó sì di àmúlò ni 31/8/1965. Ìpàdé àjọ Gbogboògbò túnń gba àtúnṣe tí ó tún ṣẹlẹ̀ sí kókó-àdéhùn 61 ní 20/12/1971. Ó di àmúlò bákan náà ni 24/9/1973. Wọ́n tún gba àtúnṣe tí ó ṣẹlẹ̀ si kókó-àdéhùn 109 ni 20/12/1965, ó sì di àmúlò ni 12/6/1968.

Àtúnṣe tí ó bá kókó-àdéhùn 23 jẹ́ kí ọmọ-ẹgbẹ́ lé si, láti mọ́kànlá wọ́n di mẹ́ẹ̀dógún. Àtúnṣe kókó-àdéhùn 27 ló pèsè àdéhùn pé nípa ìbò ọmọ-ẹgbẹ́ mẹ́sàn-án (tí wọ́n jẹ́ mọ́kànlá tẹ́lẹ̀), tí kò sí àríyànjiyàn nibẹ̀ ni yóò máa f'ẹnukò lórí ọ̀rọ̀ ààbò látàrí àwọn ìgbésẹ̀ àjọ náà. Bẹ́ẹ̀ náà ni ọmọ-ẹgbẹ́ mẹ́sàn-án (tí wọ́n jẹ́ méje tẹ́lẹ̀) àti ìbò àwọn márùn-ún tí wọ́n jẹ́ olùmẹ́gbẹ́ró ní ti ààbò bí ọ̀rọ̀ ìbò náà bá fẹ́ takókó.

Àtúnṣe tó ṣẹlẹ̀ si kókó-àdéhùn 61 ni 31/8/65 jẹ́ kí ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ ọrọ̀-ajé àti àwujọ gbòòrò sí láti méjìdínlógún sí mẹ́tàdínlọ́gbọ̀n. Àtúnṣe tó tún wáyé nígbẹ̀yín lórí kókó-àdéhùn yìí túbọ̀ jẹ́ kí ọmọ-ẹgbẹ́ lé si láti mẹ́tàdínlọ́gbọ̀n sí mẹ́rìnlélàádọ́ta.

Àtúnṣe tó bá kókó-àdéhùn 109, èyí tí ó farapẹ́ ìpínfọ̀ àkọ́kọ́ kókó-àdéhùn yìí fi ààfò tàbí ààyè pe Ìpàdé Gbogboògbò àwọn orílẹ̀-èdè tí ó jẹ́ ọmọ-ẹgbẹ́ le waye lọ́jọ́ àti níbi ti ìkó-méjì nínú mẹ́ta àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ náà bá faramọ́ lẹ́yìn ìbò gbogboògbò silẹ̀. Bákan náà ìbò àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ mẹ́sàn-án (tí wọ́n jẹ́ méje tẹ́lẹ̀) tí wọ́n ó rí sí ààbò ẹgbẹ́ pàá ṣe kókó. Ìpínfọ̀ kẹta kókó-àdéhùn 109 tí ó rì sí àtúnṣe ni Ìpàdé gbogboògbò ẹlẹ́ẹ̀kẹwàá irú èyí padà sí bí ó ṣe wà tẹ́lẹ̀. Ìpinfọ̀ náà lo mẹ́núba pàtàkì ìbò èyikeyìí nínú àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ méje tí ó ń rí sí ààbò ẹgbẹ́. Ni ìpàdé gbogboògbò ẹlẹ́ẹ̀kẹwàá irú ẹ̀ àti àṣẹ àjọ tí ó ń rí sí ààbò ẹgbẹ́ ni 1955 ni wọn ti mú ìpínfọ̀ náà ni kókó.

Àwa Ọmọ Ẹgbẹ́ Àjọ Orílé-Èdè Àgbáyé ti pinnu láti ri pé a dáàbò bo àwọn ìran tí ó ń bọ̀ l'ẹ́yìnwá-ọ̀la l'ọ́wọ́ ogun èyí tí ó wáyé l'ẹ́ẹ̀meji ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ l'ọ́tẹ̀ tàwa, tí ó sì mú ìyà aláìlẹ́gbẹ́ bá ẹ̀dá èèyàn.

A ó sì mú ẹ̀tọ́ ọmọ èèyàn l'ọ́kùn-únkúndùn, pàápàá iyì èèyàn l'áwùjọ, yálà akọ ni ò, tàbí abo. Bẹ́ẹ̀ náà ni ẹ̀tọ́ orilẹ́-èdè kan ò ní dùn ún, bí ó ti wù kí ó kéré mọ.

A ó sì tún ṣe ìgbékalẹ̀ ètò tí yóò jẹ́ kí ìdájọ́ òdodo àti ìbọ̀wọ̀fún ojúṣe kálukú ní ìbámu pẹ̀lú àkọsílẹ̀ ẹgbẹ́ àti orísun òfin àgbáyé.
Bẹ́ẹ̀ la ó ri pé ìgbé-ayé tó rọrùn ń bá àwùjọ gbogbo, tí ẹnìkan ò sí ní si ìgbèkùn.

**LÁTI JẸ́ KÍ ÀWỌN ÌPINNU YÌÍ ṢEÉṢE:**

A gbọ́dọ̀ ní ìfaradà, kí a gbé pẹ̀lú ara wa láì sí ìjà tàbí ìta.

Kí a sì tún ṣe ara wa lóṣùṣù-ọwọ̀, kí a lè gbé ìgbé àláàfíà, pẹ̀lú ààbò tó péye kárí ayé. Kí a sì ri pé a 'ò lo àwọn nǹkan ìjà wa sí èyíkéyìí lára wa ní ti ìyànjẹ, àyàfi bí ó bá jẹ́ pé yóò ṣe gbogbo wa láǹfàní bí a bá lo nǹkan ìjà náà.
Bákan náà, kí a gbìyànjú ri pé ètò ọrọ̀-ajé àti ìgbé-ayé àwa ẹ̀dá lápapọ̀ ń dára sí i.

***A ti ṣe ìlérí pé a ó jùmọ̀ sowọ́pọ̀ mú àwọn èròǹgbà yí ṣẹ.***

Àwọn ìjọba orílẹ̀-èdè wa lápapọ̀ rán aṣojú wa sí ìpàdé tí a ṣe ni ìlu San Francisco, wọ́n sì faramọ́ àdéhùn àjọ orílè-èdè àgbáyé nípa bẹ́ẹ̀ la fi dá àjọ àgbáyé kan tí a ó mọ̀ sí Àjọ Orílẹ̀-èdè Àgbáyé silẹ̀.

# Orí Kìíní

## *Ànfàní àti Ërònɡbà*

### *Kókó-àdéhùn 1*

Pàtàki Àjọ orílẹ̀-èdè àgbáyé ni ìwònyí:

1. Láti ri pé àlàáfíà àti àábò tó péye jọba lágbàáyé. Àti láti ri pé ẹnikan o halẹ̀ mọ́, ẹnikan lọ́nà tí ó lè fa àìbalẹ̀-ọkàn. Láti ri pé ìlànà tí ó bá ìdájọ́ òdodo àti òfin àgbáyé mu ni a ó fi máa yanjú ìjà káàkiri àgbáyé, nípa bẹ́ẹ̀ kò ní sí àìbalẹ̀-ọkàn l'áwùjọ ẹdá.
2. Láti ri pé ìbáṣepọ̀ ọlọ́rẹ̀ẹ́jọ̀rẹ́ wà láàrin àwọn orílẹ̀-èdè gbogbo. Kí ìbọ̀wọ̀ fún ẹ̀tọ́ ara-ẹni wa. Kí ìbáṣepọ̀ àláàfíà wà kárí-ayé.
3. Láti f'ọwọ́sọwọ́pọ̀ yanjú àìṣedéédé tí ó dé bá ètò ọrọ̀-ajé àwùjọ, àṣà tàbí ìwà ọmọlúàbí. Pẹ̀lúpẹ̀lú, láti ri pé ètò àti òmìnira ọmọ èèyàn lá ì sí èyàmèya, láàrin akọ tàbí abo, èdè, tàbí ẹsìn.
4. Bákan náà, kí ìmọ̀ àti ìṣe àwọn orílẹ̀-èdè ṣe ọ̀kan bí a bá fẹ́ kí ànfàní àti èròngbà wọ̀nyí ṣeése.

### *Kókó-àdéhùn 2*

Nínú akitiyan ẹgbẹ́ àti àwọn ọmọ ẹgbẹ́ náà lati ri pé àwọn èèyàn jẹ àwọn ànfàní tí ó wà nínú kókó-àdéhùn kìíní, àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí ni wọn yóò gbé:

1. Ìbáṣepọ̀ olórí-ò-jorì láàrin àwọn ọmọ ẹgbẹ́ l'àkóso ẹgbẹ́ náà gùn lé.
2. Gbogbo ojúṣe ti gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ fẹnukò si pé àwọn yóò ṣe nínú àdéhùn tí wọ́n ṣe yìí ni wọn gbọ́dọ̀ ṣe láti lè jànfàní

tó tọ́ si wọn bíi ọmọ-ẹgbẹ́.

3. Gbogbo èdèàìyedè tí ó wà láàrin àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ káríayé ni wọ́n gbọ́dọ̀ pári ní ìtúbí ìnùbí ni ọ̀nà tí kò fi ní pa ìbàlẹ̀-ọkàn, àti ìdájọ́-òdodo lára.

4. Gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ gbọ́dọ̀ ri pé wọn ò dún kùkùlajà mọ́ ọmọ-ẹgbẹ́ kankan nínú ìbáṣepọ̀ àwọn orílẹ̀-èdè kankan tàbí lọ́nà tí ó lòdì sí ànfàní àjọ orílè-èdè náà.

5. Gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ ló gbọ́dọ̀ gbárùkù ti Àjọ àpapọ̀ orilẹ́-èdè nínú ìgbẹ́sẹ̀ tí ó bá wà ní ìbámu pẹ̀lú àdéhùn yìí. Wọn kò sì gbọdọ̀ gbè lẹ́yìn orílè-èdè tí àjọ náà bá ń ká l'ọ́wọ́ ìbàjẹ́ kò tàbí tí ó bá fi tipá mú kí ó ṣe ẹ̀tọ́.

6. Àjọ àpapọ̀ orílè-èdè àgbáyé gbọdọ̀ ri pé àwọn orílè-èdè tí wọn kì í ṣe ọmọ - ẹgbẹ́ pàá tẹ̀lẹ́ ìlànà tí àjọ náà gbe kalẹ̀ láti ri pé àlááfíà àti ààbò to péye wà kárí-ayé.

7. Kò gbọdọ̀ si nǹkankan tí ó wà nínú àdéhùn yi ti yóò fun àjọ náà lágbára láti dá sí ọ̀rọ̀ abẹ́lé orílè-èdè kan. Bẹ́ẹ̀ náà ni àjọ náà ò gbọdọ̀ fi tipá mú ọmọ-ẹgbẹ́ láti gbé irú ìṣẹ̀lẹ̀ abẹ́lé bẹ́ẹ̀ wá láti parí. Àmọ́ o, ìgbẹ́ṣẹ̀ yi ò gbọdọ̀ pa ẹ̀tọ́ ìgbófinró àjọ náà tí ó wà ní orí kẹrin àdéhùn náà lára.

# Orí Kejì

## *Ọmọ-ẹgbẹ́*

### *Kókó-àdéhùn 3*

Àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ tí wọ́n jùmọ̀ ṣe Ìpàdé Gbogboógbò lórí ìbáṣepọ̀ orílè-èdè àgbáyé ní ìlú San Francisco ni ọmọ-ẹgbẹ́ gidi. Àwọn tí wọ́n f'ọwọ́ síwèé tí Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè gbé jáde ní 1/1/1942 náà lágbára, Bẹ́ẹ̀ ni àwọn tí wọ́n f'ọwọ́ sí àdéhùn yí tí wọ́n si ṣàtúnṣe rẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi ìlànà àti ìbámu pẹ̀lú kókó-àdéhùn 110 ṣe lágbára.

### *Kókó-àdéhùn 4*

1. Àwọn orílè-èdè tí kì í ṣe ọmọ-ẹgbẹ́ àmọ́ tí wọ́n nífèé àláàfíà náà lè darapọ̀ mọ́ àjọ náà bí wọ́n bá ti faramọ́ àdéhùn àjọ náà. Pàápàá bí ẹgbẹ náà bá ri pé irú orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ bá lè ṣe àwọn nǹkan tí ẹgbẹ́ náà ń fẹ́ wọ̀nyí.
2. Kí irú orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ tó di ọmọ-ẹgbẹ́, àjọ Ìpàdé Gbogboogbò ni wọn ó ti f'ẹnukọ̀ boya kí wọ́n gba orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀. Àmọ́, bí àjọ tó ń rí sí ààbò bá pa á láṣe pe kí wọ́n gba irú orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ sẹ́gbẹ́ ni wọ́n tó lè gbà á.

### *Kókó-àdéhùn 5*

Ọmọ-ẹgbẹ́ tí ó bá ṣẹ̀ s'ófin àjọ, tàbí ó ṣe aṣemáṣe tí ọwọ́ àjọ tí ó ń rí sí ààbọ̀ ẹgbẹ́ bá fi tẹ̀ wọ́n, ìpàdé gbogboògbò á yọ wọ́n lẹ́gbẹ́ fún ìgbà díẹ̀; gẹ́gẹ́ bí àṣẹ ti àjọ tí ó ń rí sí ààbò ẹgbẹ́ bá pa l'órí ọ̀rọ̀ náà.

### *Kókó-àdéhùn 6*

Ìpàdé gbogboògbò lè yọ ọmọ ẹgbẹ́ tí ó bá lùfin lóòrékóòre l'ónà tí ó lòdì sí àdéhùn ẹgbẹ́ kúrò l'ẹ́gbẹ́. Àmọ́ ò, ọ̀rọ̀ tí àjọ tí ó ń rí sí ààbò ẹgbẹ́ bá sọ labẹ́ gé lórí ìjìyà tó tọ́ sí arúfin bẹ́ẹ̀.

# Orí Kẹta

## *Àwọn Ẹka*

### *Kókó-àdéhùn 7*

1. Ọpọ̀ ẹ̀ka ni wọ́n dá sílẹ̀ ni àjọ orílẹ̀-èdè bíi: Ìpàdé Gbogboògbò, Àjọ aláàbò, Àjọ tí ó ń rí sí ọrọ̀-ajé àti àwùjọ, Àjọ alábòójútó, Ilé-ẹjọ́ Ìdájọ́ Òdodo àgbáyé àti olú Ilé-iṣẹ́ kan.
2. Bí ó bá yá, bí ìdí bá wà fún un, wọ́n lè dá àwọn ìsọmọgbè ẹ̀ka sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi àdéhùn yí.

### *Kókó-àdéhùn 8*

Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè àgbáyé ò ní sàì f'ààyè gba ẹnìkeni yálà ọkùnrin tàbí obìnrin láti kópa l'ááyèkááyè láì sí pé ẹnìkan gaju ẹnìkan, bó ṣé àwọn ojúlówó ẹ̀ka tàbí àwọn ẹ̀ka tí ó jẹ́ ìsọmọgbè pàápàá.

# Orí Kẹrin

## Ètò

### *Kókó-àdéhùn 9*

1. Gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ ló gbọ́dọ̀ kópa nínú Ìpàdé Gbogboògbò
2. Ọmọ-ẹgbẹ́ kọ̀ọ̀kan ò gbọdọ̀ ni jú aṣojú márùn-ún lọ nínú Ìpàdé Gbogboògbò.

## Ojúṣe àti Agbára Ẹgbẹ́

### *Kókó-àdéhùn 10*

Gbogbo ohun tí ó bá tí wà nínú àdéhùn yí tàbí tí ó farapẹ́ ojuṣẹ́ èyíkéyìí nínú ẹ̀ka ni Ìpàdé Gbogboògbò lè jíròrò lórí ẹ̀. Yàtọ̀ sí èyí, kókó-àdéhùn kejìlá pàá lè dábàá yálà sí àwọn ọmọ-ẹgbẹ àjọ orílẹ̀-èdè àgbáyé ò sì leè jẹ́ sí àjọ ààbò tàbí kí àwọn méjèèjì dábàá ìgbésẹ̀ tó yẹ.

### *Kókó-àdéhùn 11*

1. Ó ṣeéṣe kí Ìpàdé Gbogboògbò jíròrò lórí ìbágbépọ̀, ààbò tó péye, pẹ̀lú òfin tí yóò fi òpin sí fífí ohun-ìjà dún kùkùlajà Ó sì lè dábàá fún yálà ọmọ-ẹgbẹ́ tàbí àjọ tó ń rí sí ààbò ẹgbẹ́; tàbí fún àwọn méjèèjì lápapọ̀.
2. Ìpàdé Gbogboògbò lè jíròrò lórí ọ̀rọ̀ tó bá jẹ mọ́ àláàfíà àgbáyé àti ààbò tí ọmọ-ẹgbẹ́ kan bá wá fi tó Ìpàdè Gbogboògbò létí. Ó sì lè jẹ́ pé àjọ tó ń rí sí ààbò tàbí Ìpàdé gbogboògbò Ní ìbámu pẹ̀lú kókó àdéhùn 35, ìpínfọ̀ 2. yàtọ̀ sí ohun tí ó wà ní àdéhùn 12, Ìpàdé Gbogboògbò lè dábàá lórí ọ̀rọ̀ náà yálà fún orílẹ̀-èdè tàbí àwọn orílẹ̀-èdè tàbí fún àwọn méjèèjì lápapọ̀. Ọ̀rọ̀ tí ó bá yẹ kí wọ́n ṣe nǹkan sí bẹ̀ẹ̀ Ìpàdé Gbogboògbò gbọ́dọ̀ sọ fún àjọ tó ń rí sí ààbò ẹgbẹ́, yálà kí wọ́n tó jíròrò tàbí lẹ́yìn ìfinkùlukùn wọn.

3. Ìpádè Gbogboògbò lè pe àkíyèsí àjọ tí ó ń bójútó ààbò ẹgbẹ́ sí ọ̀rọ̀ tó lè mú ewu bá àlàáfíà àgbáyé àti ààbò.

4. Agbára Ìpàdé Gbogboògbò tí a kà sílè nínú kókó-àdéhùn yìí ò gbọdọ̀ dí agbára kókó-àdéhùn kẹwàá kù.

## Kókó-àdéhùn 12

1. Bí àjọ ti ó ń rí sí ààbò ẹgbẹ́ bá ń ṣe ojúṣe rẹ̀ tí ó ń parí aáwọ̀ tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ kan gẹ́gẹ́ bíi ohun tí wọ́n ní kí ó máa ṣe nínú àdéhùn, Ìpàdé Gbogboògbò kò gbọdọ̀ dábàá kankan lórí irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀, àyàfi bí àjọ tí ó ń rí sí ààbò ẹgbẹ́ bá fi ọ̀rọ̀ náà lọ̀ wọ́n ló kù.

2. Akọ̀wé-Gbogboògbò gbọdọ̀ fi ọ̀rọ̀ tó bá níí ṣe pẹ̀lú ìbálè-ọkàn àgbáyé àti ààbò àwùjọ gbogbo tó àjọ tó ń bójútó ààbò ẹgbẹ́ létí ní Ìpàdé Gbogboògbò kọ̀ọ̀kan, kí Ìpàdé Gbogboògbò tó lè ṣe ǹnkankan. Bí àjọ tí ó ń ṣàbójútó ààbò bá yanjú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ tán, yóò ṣẹ̀ṣẹ̀ tún fi tó Ìpàdé Gbogboògbò létí bákan náà. Bí kò bá wá sí ànfàní kí Ìpàdé Gogboògbò pàdé lórí ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀, àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ tí ó ṣàbojútó ààbò ni wọn ó fi tó létí, tí wọn ó sì yọwọ́-yọsẹ̀ nínú irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀.

## Kókó-àdéhùn 13

Ìpàdé Gbogboògbò ni yóò ṣètò ìgbéyèwò kí ó sì dábàá fun àǹfàní

a. Kí ìbáṣepọ̀, máa tẹ̀síwájú nínú ètò òṣèlú àgbáyé. Bákan náà kí ó rí i pé ìtẹ̀síwájú ń bá òfin àgbáyé. Kí wọ́n sì ri pé òfin náà yẹ tẹrútọmọ.

b. Kí wón ri pé ìtẹ̀síwájú àti àṣepọ̀ wà nínú ètò ọrọ̀-ajé, ìgbéayé-ẹ̀dá, àṣà, ètò-èkó àti ìlera l'ágbàáyé. Kí wọ́n ri pé kò sí ẹ̀dá tí wón fi ẹ̀tọ́ ẹ̀ dùn. Kó má sí ẹ̀yàmẹ̀yà yálà ni tẹ̀yà, akọ tàbí abo, èdè tàbí ẹ̀sìn

2. Bí Ojúṣe àti agbára Ìpàdé Gbogboògbò yóò ṣe pọ si yóò wà ni ìbámu pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ tí a ti sọ ní ìpínfọ̀ 1 (b) l'ókè ní orí kẹsàn-an àti ìkẹwàá níwájù.

### Kókó-àdéhùn 14

Nípa títẹ̀lé ìlànà kókó-àdéhùn 12, Ìpàdé Gbogboògbò lè dabàá àtúnṣe ìṣẹ̀lẹ̀ lọ́nà ti àláàfíà yóò fi jọba. Ó tún lè ṣàtúnṣe bí ó bá róye àìṣédéédé nínú ìbágbépọ̀ àláàfíà àárín àwọn orílẹ̀-èdè, tàbí ki wọ́n ri pé orílẹ̀-èdè kan ń tapá sí àdéhùn tí ó gbé ànfàní àti èròǹgbà àjọ náà ró.

### Kókó-àdéhùn 15

1. Ọdọọdún ni àjọ tí ó ń bójútó ààbò ẹgbẹ́ gbọdọ̀ máa jábọ̀ fún Ìpàdé Gbogboògbò. Ìgbéṣè ti àjọ aláàbò ti gbé láti ri pé àláàfíà jọba kárí-ayé àti ààbò pẹ̀lú gbọdọ̀ wà lára àbọ̀ ti àjọ́ náà bá jẹ́.

2. Àwọn ẹ̀ka àjọ orílẹ̀-èdè mìíràn gbọdọ̀ jẹ Ìpàdé Gbogboògbò.

### Kókó-àdéhùn 16

Ìpàdé Gbogboògbò gbọdọ̀ ri pé òun ṣe ojúṣe òun ní ìlànà àti ìbámu pẹ̀lú ìgbéṣẹ̀ tí ó wà ni orí kejìlá láti ìkẹtàlá, pẹ̀lú ìfọwọ́sí àti àdéhùn àwọn alábòójútó tí kò sì gbọdọ̀ ta àwọn agbègbè tí ò sí nínú ète ààbò ẹgbẹ́ pẹ̀lú dànù.

### Kókó-àdéhùn 17

1. Ìpàdé Gbogboògbò ni yóò ṣ'àyẹ̀wò ètò ìsúná ẹgbẹ́ tí wọn ó sì f'ọwọ́ sí i.

2. Àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ ni wọn ó máa ṣe ìnáwó ẹgbẹ́ lára owó ti Ìpàdé Gbogboògbò bá bù fún orílẹ̀-èdè kọ̀ọkan.

3. Ìpàdé Gbogboògbò ni yóò gbé ètò ìnáwó ẹgbẹ́ yẹ̀wò, tí won ó sì f'ọwọ́ sí ètò ìsúná owó ẹgbẹ́ pẹ̀lú àwọn àjọ abánibójútó tí ó wà ní kókó-àdéhùn 57 Bákan náà ni irú àyẹ̀wò ìsúná

owo irú àjọ abánimójútó bẹ́ẹ̀ náà gbọdọ̀ máa wáyé; tí wọn ó sì máa dábàá bí ó se yẹ fún àjọ abánimójútó bẹ́ẹ̀.

## Ẽtò Ìbò-Dídì

### *Kókó-àdéhùn 18*

1. Ìbò kan péré ni ọmọ-ẹgbẹ Ìpàdé Gbogboògbò lánfàní àti dì.
2. Ìdá mẹ́ta nínú ọmọ ẹgbẹ́ tí ó wá sí Ìpàdé Gbogboògbò, tí ó dìbo ni wọ́n se ìpinnu l' órí àjọ tí ó bá ṣe pàtàkí. Ọ̀rọ̀ bíi ìlàkàkà láti ri pé àlááfíà àti ààbò tó péye jọba kárí-ayé. Ìdìbò yan ọmọ-ẹgbẹ́ fì ki í ṣe ọmọ àjọ tó ń rí sí ààbò àjọ. ìdìbò yan ọmọ-ẹgbẹ́ si àjọ ọ̀rọ̀-ajé àti sí àwùjọ; ìdìbò yan alábòójútó wà lára ìpinnu ọ̀hún. Èyíkéyìí tó lè jẹ́ nínú ìdìbò yàn yí. ó gbọdọ̀ wà ni ìbámu pẹ̀lú ìpínfọ̀ 1(d) kókó-àdéhùn 86. Lára ojúṣe Ìpádè Gbogboògbò ni yíyọ ọmọ-ẹgbẹ́ tí ó bá ṣ aṣemáṣe l'ẹ́gbẹ́ fún ìgbà kan ná àti ọ̀rọ̀ to bá níí ṣe pẹ̀lú àjọ igilẹ́yìn-ọgbà àti ètò ìsúná-owó
3. Ìdá méjì nínú ìdá mẹ́ta ọmọ-ẹgbẹ́ tí ó wà ìpàdé tí ó sì dìbò ni wọ́n l'áṣẹ láti jíròrò lórí onírúurú ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ ẹgbẹ́ bí wọ́n bá ti fìmọ̀ ṣọ̀kan.

### *Kókó-àdéhùn 19*

Ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè tí ó bá jẹ owó-ẹgbẹ́ tí kò bá ì tíì san án, kò le e dìbò ní Ìpàdé Gbogboògbò bí owó to jẹ náà bá tó tàbí ju owó ọdún méjì lọ. Àmọ̀, Ìpàdé Gbogboògbò lè gba tọ̀hún láàyè láti dìbò, bí ó bá ṣàlàyé ìdí ẹ̀ tí kò fi dáwó ẹgbẹ́ ti àlàyé náà sì múnádóko

## *Kókó-àdéhùn 20*

Ọdọọdún ni Ìpàdé Gbogboògbò yóò máa pé. Bẹ́ẹ̀ sì ni, wọ́n lè pe ìpàdé lái ṣe tọlọ́dọọdún bí ìdí pàtàki bá wà fún irú ìpàdé bẹ́ẹ̀. Akọ̀wé-Gbogboògbò lè pe àkànṣe ìpàdé bí àjọ tó ń bójútó ààbò ẹgbẹ́ tàbí ọgọ̀rọ̀ ọmọ-ẹgbẹ́ bá ní kí ó pe ìpàdé.

## *Kókó-àdéhùn 21*

Ìpàdé Gbogboògbò ni yóò ṣ'òfin tiẹ̀ láàyè ọ̀tọ̀. Sáà kọ̀ọ̀kan ni ìpàdé Gbogboògbò yóò máa yan Ààre.

## *Kókó-àdéhùn 22*

Láti lè jẹ ki akitiyan rẹ̀ ó kógo já; Ìpàdé Gbogboògbò lè dá ẹ̀ka ìpàdè kékerè tí kò ní lágbára tó Ìpàdé Gbogboògbò sílẹ̀. Èyíinì bí ó bá lérò pé ó yẹ bẹ́ẹ̀ láti lè fi jẹ́ kí akitiyan òun túbọ̀ múnádóko.

# Orí Karùn-ún

## Àjọ Alábòójútó

### Ìgbékalè

***Koko-Adehun 23***

1. Méèdógún nínú ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ orílẹ̀-èdè ni yóò wà nínú àjọ alábòójútó náà. Àwọn náà ni orílẹ̀-èdè Olómìnira China,Ilẹ̀ Faransé, àpapọ̀ orílẹ̀-èdè olómìnira tí a mọ̀ si Soviet Union. Ìlú Òyìnbó àti árẹ̀wá, orílẹ̀-èdè Ireland. Bẹ́ẹ̀ náà ni àpapọ̀ àwọn ìpínlẹ̀ Amẹ́ríkà yóò jẹ́ ọmọ-ẹgbẹ́ ayéraye àjọ náà. Ìpàdé Gbogboògbò yóò wá yan ọmọ-ẹgbẹ́ mẹ́wàá mìíràn tí ó jẹ́ pé fún ìgbà kan làwọn yóò fi jẹ́ lára ọmọ àjọ alábòójútó náà. Àkàndá owó sí àpò ẹgbẹ́ fún ìtọ́jú gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ orílẹ̀-èdè fún ìbágbépọ̀ àlàáfíà, àti ààbò tó péye l'áwùjọ ẹ̀dá àti fún ààtò ẹgbẹ́ náà àti pẹ̀lú fún ìpín lọ́gbọọgba, ètó ọmọ-ẹgbẹ́ gbogbo yóò wà.
2. Ọdún méjì l' àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ alábòójútó ti ó jẹ́ pé fún ìgbà díẹ̀ ni wọn ó fi wà níbẹ̀ yóò lò. Nínú ìdìbòyàn àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ tí yóò wà níbẹ̀ fún ìgbà díẹ̀ ní ìgbà àkọ́kọ́ lẹ́yìn ti ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ alábòójútó bá ti lé kún láti mọ́kànlá sí méèdógùn, wọn ó yan méjì nínú àwọn mẹ́rin tó lé sí náà sí àjọ fún ọdún kan. Wọn kò le è tún ọmọ-ẹgbẹ́ tí ó bá ti fèyìntì yàn sí àjọ alábòójútó.
3. Gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ alábòójútó ni yoo ni asoju kookan.

### Ojúṣe àti Agbára.

***Kókó-àdéhùn 24***

1. Láti lè jẹ́ kí Àjọ alábòójútó bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ rẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹ́sẹ̀, kí ẹ̀nu àjọ náà sì lè tọ́lẹ̀, àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè fún àjọ náà l ágbára láti

ri pé ìbágbépọ̀ àlááfíà àti ààbò wà láwùjọ ẹ̀dá, kí wọ́n sì jẹ́ ki àjọ náà mọ pé àwọn (Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè) ni àwọn ń ṣojú nínú iṣẹ́ àti ìṣe wọn.

2. Kí Àjọ Alábòójútó náà máa níran bí wọ́n bá ń ṣojúṣe wọn ìdí àti èròngbà tí wọ́n fi dá àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè sílẹ̀. Àwọn kókó agbára tí wọ́n gbé wọ Àjọ Alábòójútó náà wà ní orí kẹfà, keje, Ìkẹjọ àti Ìkejìlá.

3. Àjọ náà gbọdọ̀ máa jábọ̀ bí wọ́n ṣe ń ṣiṣẹ́ tí wọ́n yàn wọ́n sí fún ìpàdé gbogbogbòò lọ́dọọdún àti lásìkò mìíràn tó bá yẹ fún àgbéyẹ̀wò.

### *Kókó-àdéhùn 25*

Àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè faramọ́ láti mú àbá Àjọ alábòójútó ṣẹ ni ìbámu pẹ̀lú àdéhùn yí,

### *Kókó-àdéhùn 26*

Láti lè rí i pé ìbágbépọ̀ àláàfíà àti ààbò wà lágbàáyé ti ifẹ̀mí àti dúkìá l' ágbàáyé sòfò yóò fi díkù, àjọ alábòójútó pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àwọn kọmití ọmọ olóógun gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà ni àdéhùn 47 yóò ṣe ìgbékalẹ̀ òfin lóri ohun-ìjà tí ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè bá ni.

## Ìdìbò.

### *Kókó-àdéhùn 27*

1. Ìbò kan péré ni ọmọ-ẹgbẹ́ àjo alábòójútó gbọdọ̀ dì.

2. Àbájáde ètò ìdìbò tí mẹ́sàn-án nínú àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ alábòójútó bá dì, tí wọ́n sì f'ẹnukò l'órí ọ̀rọ̀ kan pàtó l'Àjọ náà gbodọ̀ mú lò.

3. Àbájáde ìbò tí mẹ́sàn-án nínú àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ bá dì, pẹ̀lú tí àwọn ìbò ọmọ-egbẹ́ ayéraye ni yóò máa jẹ́ ìpinnu Àjọ Alábòójútó l'órí ọ̀rọ̀ kan. Àmọ́ gẹ́gẹ́ bí àwọn ìpinnu tí ó wà ni orí kẹfà àti èyí tí ó wà ni ìpínfọ̀ kẹta nínú kókó-àdéhùn

52 bá ṣe wí tí ó jẹ́ pé ọmọ-ẹgbẹ́ tí ọ̀rọ̀ náà bá kàn kò ní dìbò la ó tẹ̀lé

## Ìlànà.

### *Kókó-àdéhùn 28*

1. Ààtò Àjọ Alábòójútó náà gbọdọ̀ jẹ́ èyí tí yóò máa ṣ'ojúṣe rẹ̀ lọ nígbà gbogbo. Nítorí ìdí èyí l'ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ Alábòójútó ṣe gbọ́dọ̀ máa l'áṣojú nígbà gbogbo nínú ìpàdé ẹgbẹ́ náà.
2. Àjọ Alábòójútó náà gbọdọ̀ máa ṣe ìpàdé àtìgbàdégbà, nínú èyí tí ọmọ-ẹgbẹ́ tó bá wù lè máa ní aṣojú. Aṣojú náà lè jẹ́ lára òṣìṣẹ́ Ìjọba tàbí aṣojú tí wọ́n kanlẹ̀ yàn lọ sí ìpàdé ọ̀hún.
3. Àjọ Alábòójútó lè ṣe ìpàdé níbi tí ó bá wù wọ́n yàtọ̀ sí ibùjòkóó Ẹgbẹ́ bí wọ́n bá lérò pé yóò mú iṣẹ́ wọn yá.

### *Kókó-àdéhùn 29*

Àjọ Alábòójútó náà lé yan awọ̀n àjọ kéréjekéréje bí ó bá wù ú, láti lè mú iṣẹ́ àti ojúṣe rẹ̀ dára.

### *Kókó-àdéhùn 30*

Òfin ti ó bá wù Àjọ Alábòójútó náà ló lè mú lo, kódà nínú yíyan Ààrẹ Àjọ náà.

### *Kókó-àdéhùn 31*

Eyíkéyìí ninu ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè tí kì í ṣe ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ Alábòójútó lè kópa nínú ètò ìdìbò-yanjú ọ̀rọ̀ tí wọ́n bá gbé wá síwájú Àjọ Alábòójútó bí Àjọ náà bá ri pé ó kan ọmọ-ẹgbẹ́ bẹ́ẹ̀.

### *Kókó-àdéhùn 32*

Wọ́n lè pé yálà ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ Àpapọ̀ Orílẹ̀-èdè ti kì í ṣe ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ Alábòójútó tàbí orílẹ̀-èdè tí kì í ṣe ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè tí ọ̀rọ̀ tí wọ́n bá gbé wá fún àgbéyẹ̀wò Àjọ Alábòójútó bá kàn láti wá kópa nínú ìjíròrò lórí èdèàìyedè náà láì dìbò. Àjọ Alábòójútó ni yóò ṣètò tó yẹ láti ri pé orílẹ̀-èdè tí kì í ṣe ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè kópa tó tọ sí i.

# Orí Kẹfà

## *Ìparí Aáwọ̀ ní Ìtùbínnùbí*

### *Kókó-àdéhùn 33*

1. Bí aáwọ̀ tí ó lè fa àìbalẹ̀-okàn àti ewu l'ágbàáyé bá wáyé láàrin àwọn kan, ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ ni láti ri pé a dẹ́kun aáwọ̀ bẹ́ẹ̀ nípa sísọ ọ̀rọ̀ náà ni ìtùbínnùbí, kí a ṣe ònlàjà: mú ìrẹ́pọ̀ wà l'áàrin àwọn oníjà náà, ìdájọ́ òdodo tí aáwọ̀ náà yóò fi parí pátá, tàbí ọ̀nà ti àwọn oníjà náà bá rò pé ó lè f'òpin sí aáwọ̀ àárín wọn.

2. Nípa àwọn ìgbésẹ̀ báyìí, ni Àjọ Alábòójútó lè parí èdèàìyedè nígbà tí Àjọ náà bá rò pé ó tọ́nà.

### *Kókó-Àdéhùn 34*

Àjọ Alábòójútó lè ṣe ìwádìí ohun tó fa aáwọ̀ tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó lè dá wàhálà sílẹ̀; tàbí fa aáwọ̀ lágbàáyé, láti rí ìdánilójú pé aáwọ̀ tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ náà kò leè mú ìpalára bá ìbágbépọ̀ àláàfíà àti ààbò àgbáyé.

### *Kókó-àdéhùn 35*

1. Eyíkéyìí nínú ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè ló lè fi aáwọ̀ tí ó bá wà láàrin àwọn kan; tó yálà Àjọ Alábòójútó tàbí Ìpàdé Gbogboògbò létí. Pàápàá bí ó bá jọ irú aáwọ̀ tí a tọ́ka sí ní kókó-àdéhùn 34.

2. Orílẹ̀-èdè tí kì í ṣe ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè náà lè pe yálà àkíyèsí Àjọ Alábòójútó tàbí Ìpàdé Gbogboògbò sí èdèàìyedè, pàápàá bí ó bá jẹ́ ọ̀kan lára àwọn oníjà náà. Eyíinì bí orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ bá ti faramọ́ ìparí aáwọ̀ náà ni ìtùbínnùbí bí ó ṣe wà nínú àdéhùn yí.

3. Ohunkóhun tó lè ṣẹlẹ̀ ní ìpàdé Gbogboògbò látàrí ẹjọ́ tàbí ọ̀rọ̀ tí wọ́n gbé wá bá a fún ìparí lábẹ́ kókó-àdéhùn yí gbọdọ̀ wà ní ìbámu pẹ̀lú kókó-àdéhùn ìkokànlá àti ìkejìlá ni.

### *Kókó-àdéhùn 36*

1. Àjọ Alábòójútó lè ṣàtúnṣe sí kókó-àdéhùn 33 tàbí irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ tí a tọ́kasí nínú àdéhùn náà; pàápàá tí ó bá farapẹ́ irú aáwọ̀ tí a mẹ́nubà níbẹ̀.

2. Àjọ Alábòójútó gbọdọ̀ ṣàmúlò ìgbésẹ̀ ti àwọn ònííjà náà ti gbé tẹ̀lẹ̀ láti ri pé ìjà náà parí.

3. Bí Àjọ Alábòójútó bá ń dábàá, ó gbọdọ̀ mọ̀ pé ìjà tí ó bá jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ òfin gẹ́gẹ́ bíi òfin, ilé-ẹjọ́ adájọ́ òdodo ni ó yẹ kí ó darí ẹ̀ sí; ni ìbámu pẹ̀lu òfin Ilé-ẹjọ́ náà.

### *Kókó-àdéhùn 37*

1. Bí ìjá àárín àwọn ònííjà náà pàápàá, tí ìjá wọn bá jọ irú èyí tí a tọ́kasí ni kókó-àdéhùn 33; kò bá ṣee parí nípa ìlànà ìparí-ìjà nínú àdéhùn ọ̀hún, ọ̀dọ̀ Àjọ Alábòójútọ́ ni kí wọ́n darí àwọn aláìjàńgbúlá náà sí.

2. Bi Àjọ Alábòójútó bá rìi pé bí ìjà náà bá n lọ bẹ́ẹ̀, ó lè fa ìpalára bá ìbágbépọ̀ aláàfíà àti ààbò àgbáyé, ojúṣe rẹ̀ ni bóyá kí ó gbé ìgbésẹ̀ ní ìbámu pẹ̀lú kókó-àdéhùn 36 tàbí kí o dábàá tó tọ́ tí ọ́ mọ̀ pé yóò fi òpin sí aáwọ̀ náà.

### *Kókó-àdéhùn 38*

Láì figbá-kan-bọ̀kan-nínú nípa ìgbékalẹ̀ kókó-àdéhùn 33 si 37 Àjọ Alábòójútó lè dábàá ìparí ìjà ni ìtùbíńnùbí, bí àwọn ònííjà náà bá faramọ́ ọ bẹ́ẹ̀.

# Orí Keje

***Ìgbésẹ̀ tí a lè gbé láti dènà àìbalẹ̀ ọkàn dídá - ìbágbépọ̀ - àláàfíà - rú àti ìwà ìdúnkookòmọ́ ra-ẹni.***

***Kókó-àdéhùn 39***

Bí Àjọ Alábòójútó bá ti róye ìgbésẹ̀ tí ó lè fa àìbalẹ̀-ọkàn; dídá-ìbágbépọ̀-àláàfíà-rú àti ìwà ìdúnkookò-mọ́ra-ẹni, ó gbọ́dọ̀ dábàá tàbí pinnu ìgbésẹ̀ tó yẹ kíá ní ìbámu pẹ̀lú àwọn kókó-àdéhùn 41 àti 42 láti jẹ́ kí ìbàlẹ̀-ọkàn àti ààbò wà kárí-ayé tàbí dá ìbàlẹ̀-ọkàn àti ààbò padà ságbààyé.

***Kókó-àdéhùn 40***

Láti ri pé ìnáwó ìjà náà ò tún rú tú mọ́; Àjọ Alábòójútó lè pé àwọn oníjà náà pọ̀ kí wọ́n sì faramọ́ ìgbésẹ̀ náà bí ó ṣe tọ́ àti bí ó ṣe yẹ. Kí wọ́n tó pinnu tàbí dábàá tí ó wà ní kókó-àdéhùn 39 yẹn. Àǹfàní bẹ́ẹ̀ kò gbọdọ̀ fi ààfo àìfọkàntán sílẹ̀ nípa fífi ẹ̀tọ́, tàbí ipò àwọn oníjà náà dùn wọ́n. Àjọ Alábòójútó gbọdọ̀ ṣe àkíyèsí bí ìgbésẹ̀ wọ̀nyẹn bá kùnà, tí kò leè pa ná aáwọ̀ bẹ́ẹ̀.

***Kókó-àdéhùn 41***

Àjọ Alábòójútó lè gbé ìgbésẹ̀ tó bá tọ́ láti ri pé ìpinnu oun látàri kí àláàfíà jọba fẹsẹ̀múlẹ̀ àmọ́ o, kò gbọdọ̀ lo ohun ìjà rárá. Ó sì lè pe àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè láti gbé ìgbésẹ̀ tó yẹ. Lára irú ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni láti mu òjòjò bá ètò ọrọ̀-ajé àwọn ètò ìrìnà ojú-irin, orí-omi, òfúrufú ìfiwéṣọwọ́, ìtẹwáyà, rédíò àti àwọn ọ̀nà ìgbàbára-ẹni-sọ̀rọ̀ mìíràn, Bẹ́ẹ̀ náà; kí ìfòpinsí ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú orílẹ̀-èdè aláwìífùn-ìfẹ́ bẹ́ẹ̀ wà.

***Kókó-àdéhùn 42***

Àìmọ̀ bí Àjọ Alábòójútó bá rí pé àwọn ìgbésẹ̀ tí ó wà ní kókó-àdéhùn 41 bá fétè tàbí fé fetè, ó lè gbéjà ko orílẹ̀-èdè tó

bá tàpá sí òfin lóférufú, l'ójú-omi tàbí l'órí-ilẹ̀ láti ri pé ibágbépọ̀ àlááfíà àti ààbò j'ọba l'ágbàáyé. Irú ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ nípa ìṣàfihàn, tàbí ìdínàmọ́.irú orílẹ̀-èdè béè yálà l'ójú òfurufú, l'órí-òkun, tàbí l'órí-ilẹ̀ tí ó jẹ tí ọmọ-ẹgbẹ́ Ajọ àpapọ̀ àgbáyé.

## *Kókó-àdéhùn 43*

1 Gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ àgbáyé ni ó gbodọ̀ jẹ́jẹ̀ẹ́ pé àwọn yóò pèsè fún àwọn ọmọ-ogun àwọn. Àjọ Alábòójútó wọn ó ṣe ìrànwọ́ oríṣiríṣi bíi ìfààyè àtigbàlọ láti ri pé ìgbẹ́pọ̀ àlááfíà àti ààbò àgbáyé jọba.

2. Irú àdéhùn tàbí àdéhùn bẹ́ẹ̀ yóò rí sí iye tàbí irú ọmọ-ogun. bí wọ́n ṣe gbáradì sí àti ibi tí wọ́n wà lápapọ̀. Bẹ́ẹ̀ ni irú àwọn àǹfàní àti ìrànwọ́ tí won ó pèsè pàá kò ní gbẹ́yìn.

3. Àjọ alábòójútó gbọdọ̀ ri pé ìjíròrò wáyé l'órí àdéhùn tàbí àwọn àdéhùn náà. Ìfẹnu-àdéhùn náà jóná gbọdọ̀ jẹ l'áàrín Àjọ Alábòójútó àti àwọn ọmọ-ẹgbẹ́. Awọ̀n orílẹ̀-èdè tí wọ́n l'áṣẹ ìfọwọ́sí ni wọn ó f'aṣẹ́ sí i ni ìbámu pẹ̀lú ìlànà òfin ilé oníkálukú.

## *Kókó-àdéhùn 44*

Bí Àjọ Alábòójútó bá ti pinnu láti fi tipá mú orílẹ̀-èdè tí ó bá tàpá sófin, ki ó ṣe bẹ́ẹ̀ ki ó tó ṣẹ̀ṣẹ̀ pe ọmọ-egbẹ́ tí kò ni aṣọjú ni ìpàdé ki ó pèsè ọmọ-ogun gẹ́gẹ́ bi ojúṣe gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ tí ó wà nínú kókò-àdéhùn 43 ki ó wá ṣẹ̀ṣẹ̀ pe ọmọ - ẹgbẹ bẹ́ẹ̀, bí ó bá wù u láti kópa nínú ìpinnu Àjọ Alábòójútó pe kí àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ fi ọmọ-ogun wọn ránṣẹ́ sí Àjọ Alábòójútó náà.

## *Kókó-àdéhùn 45*

Láti lè jẹ́ kí ó ṣeéṣe fún Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè láti gbé ọmọ-ogun dìde l'ọ́gán, àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ gbọdọ̀ tètè kó àwọn ọmọ-ogun òfúrufú orílẹ̀-èdè tó wà nílẹ̀ ná mọ́ tàwọn àgbáyé, kí iṣẹ́ lè yá. Ni ìbámu pẹ̀lú àdéhùn tàbí àwọn àdéhùn tí á ti tọ́ka sí nínú kókó-àdéhùn 43, ni ìgbáradì ètò, àti àpapọ̀ iye ọmọ-ogun bẹ̀ẹ gẹ́gẹ́ bí Àjọ Alábòójútó àti Kọmití àwọn ọmọ-ogun ṣè pinnu.

## Kókó-àdéhùn 46

Àjọ Alábòójútó pẹ̀lú ìrànwọ́ àwọn omo-ogun ni yóò ṣe ètó àwọn ọmọ-ogun

## Kókó-àdéhùn 47

1. Wọ́n gbọdọ̀ dá Kọmiti ọmọ-ogun kan sílẹ̀ tí yóò máa gba Àjọ Alábòójútó nímọ̀ràn, tí yóò sì máa ràn án l'ọ́wọ́ bákan náà, látàrí ọ̀rọ̀ gbogbo tí ó jẹ́ mọ ohun tí Àjọ Alábòójútó bá ń fẹ́ nípa àwọn nǹkan ìjà láti le máa rí pé ìbágbépọ̀ àláàfíà àti àabò tó péye; ìlé'pàṣẹ, àti ìlédáàbòbò àwọn ọmọ-ogun tí wọ́n fún un àti ìṣètò tó ye lórí ìpèsè ohun-ìjà àti gbígba ohun-ìjà kúrò l'ọ́wọ́ àwọn ọmọ-ogun lẹ́yìn ìjà náà wà.

2. Àwọn aláṣẹ nínú àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ Alábòójútó tàbí aṣoju wọn ni yóò wà nínú Kọmiti àwọn ọmọ-ogun náà. Ìgbà tí iṣẹ́ bá wà fún ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè tí kò ni aṣojú ayéraye nínú Kọmiti náà. Kọmiti náà lè pè wọ́n fún ìrànwọ́ tó yẹ.

3. Àjọ Alábòójútó ni yóò máa pàṣẹ nípa àatò èyíkéyìí nínú àwọn ọmọ-ogun tí ó wà lábẹ́ àkoso rẹ̀. Lẹ́sẹẹsẹ ni àatò àṣẹ bẹ́ẹ̀ yóò máa wáyé.

4. Lẹ́yìn tí àwọn náà bá ti fikùnlukùn pẹ̀lú Àjọ Alábòójútó àti àwọn àjọ agbègbè kọ̀ọ̀kan, àwọn ọmọ-ogun náà lè dá Komiti agbègbè kọ̀ọ̀kan sílẹ̀ káàrkiri.

## Kókó-àdéhùn 48

1 Gbogbo ọmọ-ẹgbẹ̀ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè tàbí ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn; bí ó bà ṣe wu Àjọ Alábòójútó; ni wọ́n ó gbèé ìgbésẹ̀ tó yẹ láti ri pé ìbágbépọ̀ àláàfíà àti àabò-àgbáyé wà láwùjọ gbogbo.

2. Tàárà ni àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè yóò mú irú ìpinnu bẹ́ẹ̀ ṣẹ lái ku ẹnikan. Wọ́n sì lè mu ìpinnu bẹ́ẹ̀ ṣe nípa akitiyan wọn nínú ẹgbẹ́ orísirísi l'ágbàáyé tí káluku won ti jẹ́ ọmọ-ẹgbẹ́.

## *Kókó-àdéhùn 49*

Àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè gbọdọ̀ fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú Àjọ Alábòójútó láti ri pé Àjọ Alábòójútó ṣe àṣeyege nínú ìgbésẹ̀ àti ìpinnu rẹ̀.

## *Kókó-àdéhùn 50*

Bí Àjọ Alábòójútó bá gbé ìgbésẹ̀ kan láti dẹ́kun ìwà ìbàjẹ́ orílẹ̀-èdè kan, ti ìgbésẹ̀ náà se bí ẹni pa yálà ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè tàbí èyí ti kì í ṣe ọmọ-ẹgbẹ́ náà lára, látàrí ètò ọrọ̀-ajé, irú orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ ní ànfàní láti gbé ìṣòrokíṣòro ti irú ìgbésẹ̀ tí Àjọ náà bá gbé wá siwájú ẹ̀ láti bá a wá ojútùú sí àwọn ìṣòro rẹ̀.

## *Kókó-àdéhùn 51*

Kò sí ibi kan nínú àdéhùn yí tó lè f'ojú tẹ́mbẹ́lú ètò àti ìdáàbò-bo-ara-ẹni àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè bí ẹnìkan bá gbógun ti wọ́n; títí Àjọ Alábòójútó yóò fi gbé ìgbésẹ̀ tó yẹ; nipa pé ìbágbé àláafíà àti àabò wa kári-ayé. ọmọ-ẹgbẹ́ gbọdọ̀ fi ìgbésẹ̀ tí wọ́n gbé láti dáàbò bo ara wọn tó Àjọ Alábòójútó létí lọ́gán. Bẹ́ẹ̀ sì ni ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀ ò gbọdọ̀ pa àṣẹ àti ojúṣe Àjọ Alábòójútó lára. Kí Àjọ náà: ni ìbámu pẹ̀lú àdéhùn yí gbé ìgbésẹ̀ tó tọ́ láti ri pé ìbágbépọ̀ àláafíà àti àabò wà kári-ayé.

# Orí Kẹ́jọ

## Ààtò Agbègbè

### *Kókó-àdéhùn 52*

1. Kò sí ibikan nínú àdéhùn yí tí ó lè dènà ààtò agbègbè tàbí tí ẹka kéréjekéréje bí ó bá jẹ láti jẹ́ kí ìbàgbépọ̀ àláàfíà àti ààbò wà ni. Bí ìgbésẹ̀ agbègbè ọ̀hún ò bá lòdì sí ètò àti èrò Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè; dẹ́édẹ́ ló ṣe.

2. Àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ tí ó bá fẹ́ ṣètò irú ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀ tàbí dá ẹka kéréjekéréje láti bójútó ọ̀rọ̀ tí ó ní ṣe pẹ̀lú ìbágbépọ̀ àláàfíà àti ààbò gbọdọ̀ ri pé àwọn ń parí aáwọ̀ ààrín àwọn oníjà ni ìtùbínnùbí kí wọn tó fi tó Àjọ Alábòójútó létí.

3. Àjọ Alábòójútó gbọdọ̀ máa ṣe àtìlẹyìn fún àwọn ẹka agbègbè láti ri pé wọ́n ń parí aáwọ̀ láàrín àwọn agbègbè nípa irú ètò ìparí ìjà bẹ́ẹ̀. Èyí le ṣeése nípa pé kí àwọn oníjà náà gbé ìgbésẹ̀ láti parí ìjà náà tàbí kí Àjọ Alábòójútó bá wọn dá sí i.

4. Kókó-àdéhùn yí kò lòdì sí ìgbékalẹ̀ àwọn kókó-àdéhùn 34 àti 35

### *Kókó-àdéhùn 53*

1. Àjọ Alábòójútó lè ṣe àmúlò ààtò agbègbè wọ̀nyí níbi tí ó bá yẹ láti lè fi àṣẹ rẹ̀ múlẹ̀. Àmọ́ àwọn ẹka agbègbè kò gbọdọ̀ dá nǹkankan ṣe láì gbàṣẹ lọ́dọ̀ Àjọ Alábòójútó. Àfi tí ó wà nínú ẹ̀ ni bí ó bá jẹ́ pé ọ̀tá ṣígun gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà ní ìpínfọ̀ kejì ni abẹ́ kókó-àdéhùn yìí; tí wọ́n pèsè fún ìmúṣẹ kókó-àdéhùn 107; tàbí láti ṣètò àkọtun láti ri pé wọn kò gbógun ti irú orílẹ̀-èdè tí ó gbógun náà. Títí di igbà tí ọ̀rọ̀ náà bá dà bẹ́ẹ̀, ìjọba orílẹ̀-èdè tí ọ̀rọ̀ náà bá kàn, lè rawọ́ ẹ̀bẹ̀ sí Àjọ náà fún ìrànwọ́ láti ri pé orílẹ̀-èdè tí ó gbógun náà d'áwọ́ dúró

2. Àwọn tí a tọ̀ka sí bí ọtá nínú ìpínfọ̀ kìíní kókó-àdéhùn yì ni àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n gbógun/lòdì sí àwọn aṣojú Àjọ nínú ìpàdé àdéhùn yí.

## *Kókó-Àdéhùn 54*

Oríṣiríṣi ètò ti ó n lọ tàbí ti àwọn agbègbè ń gbà l'érò ni wọ́n gbọ̀dọ̀ má fi tó Àjọ Alábòójútó létí láti ri pé ìbágbépọ̀ àlááfíà àti àbò wà kárí-àyé

# Orí Kẹsàn-án

## Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ Ọrọ̀-Ajé àti Àwùjọ-Àgbáyé

### Kókó-àdéhùn 55

Bí ó bá wá lérò láti sààtò bí nǹkan yóò ṣe máa lọ déédé èyí tí ó jẹ́ dàndàn fún ìbásepọ̀ àláàfíà láàrín àwọn orílẹ̀-èdè yóòkù; a gbọdọ̀ ri pé ìbọ̀wọ̀-fún-ara-ẹni, àti ìṣọkàngírí àwọn èèyàn, gbogbo àwọn nǹkan wọ̀nyi ni Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè gbọdọ̀ gbé láruge:

a. Ki ìgbé-ayé tó dára wa, kí ìṣẹ tó jẹ ojú iṣẹ́ wà, kí ìgbé-ayé rọrùn, ki ìtẹ̀síwájú bá ètò ọrọ̀ ajé àti agbègbè ẹ̀dá.

b. Kí a rí sí ìṣọro àìsédéédé ètò ọrọ̀-ajé, ìlera, àti àwọn ìṣoro bẹ́ẹ̀. Ki àṣepọ̀ l'áàrín àṣà àti ètò ẹ̀kọ́ àgbáyé wà; àti pẹ̀lú:

d. Ìbọ̀wọ̀fún-ara-ẹni, kí a sì ri pé a 'ò fẹ̀tọ́ ẹnikẹni dùn ún. Ki kálukú ni òmìnira tó péye lái sí ìtanú ẹ̀yà kan, lái fí pé ẹnikan jẹ akọ tàbí abo ṣe, èdè tàbí ni tẹlẹ́sìmẹ́sìn.

### Kókó-àdéhùn 56

Gbogbo ẹgbẹ́ ló jẹ́jẹ̀ẹ́ láti f'ọwọ́sọwọ́pọ̀ pẹ̀lú Àjọ náà fún àṣeyọrí si daada bí wọ́n ṣe gbé e kalẹ̀ ní kókó-àdéhùn 5.

### Kókó-àdéhùn 57

1. Gẹ́gẹ́ bí ìpèsè tó wà nínú kókó-àdéhùn 63, gbogbo ẹgbẹ́ tí wọ́n dá sílẹ̀ nípa ìfẹnukò láàrín àwọn ìjọba tí wọ́n jẹ́ ọmọ-ẹgbẹ́ gbọdọ̀ rí sí ìlodéédé ètò ọrọ̀-ajé àwujọ; àṣà, ẹ̀kọ, ètò ìlera; àti àwọn nǹkan kòṣéémánìí bẹ́ẹ̀ gbogbo. Gẹ́gẹ́ bíi ìlànà Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè; bí ó bá ti wà ni ìbámu pẹ̀lú kókó àdéhùn 63.
2. Irú àjọ tí ó mú ìbásepọ̀ ṣeése pẹ̀lú Àjọ àpapọ̀ àgbáyé la ó pè ní ògúnná-gbòǹgbò.

### *Kókó-àdéhùn 58*

Àjọ nàà gbọdọ̀ dábàá fún àjọṣepọ̀ àwọn ètò àti akitiyan àwọn àjọ kéréjekéréje tí a yà s'ááyè ọtọ.

### *Kókó-àdéhùn 59*

Àjọ náà gbọdọ̀ gbé ìgbésẹ̀ láti ri pé ìfikùnlukùn wà níbi tí ó bá ti yẹ láàrín àwọn orílẹ̀-èdè ti dida àjọ kéréjekéréje ti a yà sọ́tọ̀ tuntun kọkan sílẹ̀ ki ìdí ti ó wà ni kókó àdéhùn 55 le kẹ́sẹjárí.

### *Kókó-Àdéhùn 60*

Ojúṣe ìpàdé Gbogboògbò ní láti ri pé àjọ náà ń ṣ ojú ẹ̀ gégé bí ó ṣe wà ní orí yìí. Bẹ́ẹ̀ náà ni abẹ́ àṣẹ ìpàdé Gbogboògbò ni ètò ọrọ̀-ajé àti Àjọ Alábòójútó yóò wà gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà ni orí kẹ̀wàá.

# Orí Kẹwàá

## *Ìgbìmọ̀ Ètò Ọrọ̀ Ajé àti Àwùjọ Àtò Àkọ́jọ*

***Koko-adehun 61***

1. Èèyan mẹ́rìnlélàádọ́ta nínú ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ Àpapọ̀ orílẹ̀-èdè ti ìpàdé Gbogboògbò .bá dìbò ni yóò wà nínú ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé àwujọ náà.

2. Méjìdínlógún nínú ọmọ ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀ - ajé ati àwùjọ ni wọn ó máa dìbò yàn ní ìbámu pẹ̀lú ìpínfọ̀ kẹta lọ́dọọ́dún fún odun mẹ́ta gbáko. Wọ́n á tún dìbò lẹ́sẹ̀kẹ́sẹ̀ yan ọmọ-ẹgbẹ́, ti ó fẹ́ fẹ̀yìntì, torí òun pàá yẹ lẹ́ni wọ́n lè dìbò yàn.

3. Ní ètò ìdìbòyàn àkọ́kọ́ lẹ́yìn ti ọmọ-ẹgbé Ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé àti àwùjọ bá ti lé láti orí mẹ̀tàdínlọ́gbòn si mẹ́rìnlélàádọ́ta ni àpapọ̀ pẹ̀lú àwọn ọmẹ-ẹgbẹ́ ti wọ́n dibò yàn si ààyè àwọn mẹ́sàn-án tí wọ́n ti lo àkókò wọn tán nípò lọ́dún náà. Léyìn náà ni wọn o ṣẹ̀ṣẹ̀ dìbò yan ọmọ-ẹgbẹ́ mẹ́tàdínlógbọ̀n láfìkún. Òpin ọdun l'àkókò ipò àwọn mẹ́sàn-án nínú àwọn mẹ́tàdìnlọ́gbòn tí wọ́n fi kún un yóò d'ópin . Bẹ́ẹ̀ náà làkókò àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ mésàn-án mìíràn nipò ni ìbámu pẹ̀lú ètò ti Ìpàdé Gbogboògbò ti ṣe.

4. Ọmọ-ẹgbẹ́ Ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé àti àwùjọ kọ̀ọ̀kan ni yóò ni aṣojú kọ̀ọ̀kan.

**Ojúṣe àti Agbára**

***kókó-àdéhùn 62***

1. Ìgbìmọ̀ Ètò ọrọ̀-ajé àti Àwùjọ lè dábàá ìwádìí ìjìnlẹ̀ ọmọ-ẹgbẹ́ lórí àwọn ọ̀rọ̀ tó ṣẹlẹ̀, ètò ọrọ̀-ajé, àwùjo, àṣà. ẹ̀kọ́, ìlera, àti àwọn tó farajọ ìwọ̀nyí. Ìpàdé Gbogboògbò ni won yóò f'àbò àbá wọn tó létí, òun ni yóò fi ọ̀rọ̀ náà tó àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè àti ìgbìmọ̀ kéréjekéréje ti a kanlẹ̀ dá sílẹ̀ létí.

2. Ó lè dá àwọn àbá tí yóò ri pé ìtẹ̀síwájú ń ba ìbọ̀wọ̀fún àti àmúṣe ètò ọmọ èèyàn àti ìdánǹdè fún gbogbo ẹ̀dá.

3. Ó lè f'ẹnukò ṣe àgbékalẹ̀ òfin, kí wọ́n sì gbé e síwájú Ìpàdé Gbogboògbò, lórí ọ̀rọ̀ tí ó bá wà ní ìkáwọ́ Ìpàdé náà.

4. Ó lè pe ìpàdè àgbáyé gẹ́gẹ́ bí òfin tí Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè ṣe lórí ọ̀rọ̀ tí ó bá wà ní ìkáwọ́ rẹ̀.

### *Kókó-àdéhùn 63*

1. Ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé àti àwùjọ lè bá èyíkèyìí nínú àwọn àjọ kéréjekéréje tí a ti sọ nípa 'ẹ̀ ní kókó-àdéhùn 57 ṣe àdéhùn, kí wọ́n sì sọ àwọn ìgbésẹ̀ tí irú àjọ bẹ́ẹ̀ yóò gbé tí yóò ṣe ní àṣepọ̀ pẹ̀lú Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè. Ìpàdé Gbogboògbò ló gbọdọ̀ fọwọ́ sí irú àdéhùn bẹ́ẹ̀.

2. Ó lè máa ṣe àkóso ojúṣe àwọn àjọ tí a kanlẹ̀ dá sílẹ̀ náà nípa ìfikùnlukùn àti-dídá àbá pẹ̀lú irú àjọ kéréje bẹ́ẹ̀ Àti nípa fifi tó Ìpàdé Gbogboògbò àti àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè létí.

### *Koko-adehun 64*

1. Ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé àti àwùjọ lè gbé ìgbésẹ̀ tó yẹ láti máa rí ìjábọ̀ ojúṣe àwọn àjọ kéréjekéréje náà lóòrèkóòre. Ó lè ṣe ètò pẹ̀lú àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè àti àwọn àjọ kéréjekéréje tó fẹsẹ̀ rinlẹ̀ láti máa rí àbò lórí ìgbésẹ̀ tí wọ́n gbé. Èyí yóò jẹ́ kí àbá rẹ̀ lórí ọ̀rọ̀ tó wà ní ìkáwọ́ ẹ̀ gẹ́gẹ́ bí Ìpàdé Gbogboògbò ti ṣe é, ṣe é se.

2. Ó lè fi àwọn àkìyésí'ẹ̀ lórí ìjabọ̀ náà tó Ìpàdé Gbogboògbò lẹ́tí.

### *Kókó-àdéhùn 65*

Ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé àti àwùjọ lè fi ìṣẹ̀lẹ̀ tó ń ṣelẹ̀ tó Àjọ alábòójútó létí kí ó sì máa ran Àjọ alábòójútó l'ọ́wọ́ bí ó bá fẹ́ mọ̀ nípa nǹkakan.

### *Kókó-àdéhùn 66*

1. Ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé àti àwùjọ yóò ṣe àwọn nǹkakan tí ó wà ní ìkáwọ́ ẹ̀. Àwọn ojúṣe ìgbìmọ̀ náà gbọdọ̀ wà ní ìbámu pẹ̀lu àwọn àbá Ìpàdé Gbogboògbò
2. Bí àwọn ọmọ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè àjọ kéréjekéréje bá ní kí wọ́n ṣe nǹkankan, Ìgbìmọ̀ náà gbọdọ̀ gba àṣẹ l'ọ́wọ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè kí wọ́n tó ṣe nǹkan náà.
3. Yóò máa ṣe àwọn ojúṣe mìíràn gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe gbé e kalẹ̀ nínú àdéhùn yí. Ó sì lè jẹ́ ìlànà Àpapọ̀ Gbogboògbò ní wọn yóò tẹ̀lé.

## *Ìdìbò*

### *Kókó-àdéhùn 67*

1. Ẹyọ ìbò kan ṣoṣo ni ọmọ-ẹgbẹ́ ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé kọ̀ọ̀kan gbọdọ̀ dì.
2. Ọ̀gọ̀rọ̀ ọmọ-ẹgbẹ́ tí ó bá wá sí ìpàdé tí wọ́n sì dìbò ni yóò máa fẹnu ìpinnu Ìgbìmọ̀ ọrọ̀-ajé àti àwùjọ jọ́ná.

## Ètò

### *Kókó-àdéhùn 68*

Ìgbìmọ̀ ọrọ̀-aje àti àwùjọ ni yóò dá Ìgbìmọ̀ tí yóò máa ṣàátò ìgbìmọ̀ náà sílẹ̀. Àti pẹ̀lú láti máa sààbò bò ẹ̀tọ́-ẹ̀dá àti Ìgbìmọ̀ ẹgbẹ́ tí ó farapẹ́ ẹ ní ojúṣe.

### *Kókó-àdéhùn 69*

Ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé àti àwùjọ lè pe ẹnìkẹni nínú ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè láti wá kópa nínú ìpàdé rẹ̀ lórí ọ̀rọ̀ yówù tí ó bá ti kan ọmọ-ẹgbẹ́ náà láì jẹ́ pé wọ́n fìbò yàn án.

### *Kókó-àdéhùn 70*

Ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé àti àwùjọ lè ṣe ètò láti lè jẹ́ kí àwọn aṣojú àjọ kéréjekéréje tí a kanlẹ̀ dá sílẹ̀ kópa láì jẹ́ pé wọ́n dìbò yàn wọ́n nínú ìpàdé wọn. Bákan náà ni ó lè gba àwọn ìgbìmọ̀ tí ó dá sílẹ̀ bi aṣojú ẹ̀ láti wá kópa nínú ìpàdé àwọn àjọ kéréjejéréje.

### *Kókó-àdéhùn 71*

Ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé àti àwùjọ lè ṣààtò ìfikùnlukùn pẹ̀lú àwọn ẹgbẹ́ aládàáni ti ọ̀rọ̀ tí ó kan ìgbìmọ̀ náà jẹ lógún. Irú ètò bẹ́ẹ̀ lè wáyé láàrín ìgbìmọ̀ náà àti àwọn ẹgbẹ́ lágbàáyé. Ó sì lè jẹ́ pẹ̀lú àwọn ẹgbẹ lórílẹ̀-èdè gbogbo lẹ́yìn tí wọ́n bá ti fi tó àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè létí.

### *Kókó-àdéhùn 72*

1. Ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé àti àwùjọ l'ágbára láti ṣe òfin àti ìlànà ti ìgbìmọ̀ náà yoo tẹ̀le títí kan yíyan Ààrẹ Ìgbìmọ̀ náà.
2. Ìgbìmọ̀ ètò ọrọ̀-ajé yóò máa ṣe ìpàdé gẹ́gẹ́ bí òfin ìgbìmọ̀ náà, lára èyí tó jẹ́ ètò ìpèsí-ìpàdé bí ọ̀pọ̀ ọmọ-ẹgbẹ́ bá ti f'ọwọ́ sí i pé kí wọ́n pe ìpàdé.

# Orí Kọkànlá

## *Abájáde Ìpàdé nípa àwọn Orílẹ̀-Èdè tí wọ́n kò Ì dì Olómìnira*

### *Kókó-àdéhùn 73*

Ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè tí ó ti ń ṣàkóso tàbí ṣe /ń ṣàkóso àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n ò ì tíì lè dá ìjọba ara wọn ṣe gbọdọ̀ mọ̀ pé kókó ni ọrọ̀ èèyàn irú orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ gbodọ̀ jẹ́ sí wọn. Bẹ́ẹ̀ náà, ọmọ-ẹgbẹ́ bẹ́ẹ̀ gbọdọ̀ ri ìfọkàntàn nípa ojúṣe rẹ̀ lóri irú orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ ni ìbámu pẹ̀lú ìdásílẹ̀ àdéhùn yí tí ó sọrọ̀ bá ìbágbépọ̀ àláàfíà àti ààbò lágbààyé. Láti mú èyí ṣẹ, àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ gbodọ̀ ri pé àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí wà letò:

a. Kí wọ́n ri pé wọ́n b'ọwọ̀ Àṣà, ètò-ìṣèlú, ètò ọrọ̀-ajé àwùjọ, àti ìtẹ̀síwájú ètò-ẹ̀kọ́ àwọn èèyàn orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀. Ki wọ́n ri pé wọ́n ń ṣètò; kí wọ́n si máa dáàbò bò wọ́n l'ọ́wọ́ ìyànjẹ.

b. Kí wọ́n ri pé àwọn èèyàn béè ní ìjọba ti wọn. Ọmọ-ẹgbẹ́ sì gbọdọ̀ ri pé wọ́n ràn wọ́n l'ọ́wọ́ láti ni ìtẹ̀síwájú nínú ètò-ìṣèlú gẹ́gẹ́ bí àwùjọ kọ̀ọ̀kan bá ṣe gbà.

d. Kí wọ́n ri pé ìgbépọ̀ àláàfíà àti ààbò túbọ̀ wà lágbààyé.

e. Kí wọ́n ṣakitiyan ri pé ìtẹ̀síwájú bá àwùjọ bẹ́ẹ̀ nínú ìwádìí, àti ìbáṣepọ̀ àláàfíà pẹ̀lú ara wọn. Bẹ́ẹ̀ náà ni wọn gbọdọ̀ ri pé irú ìbáṣepọ̀ bẹ́ẹ̀ wà pẹ̀lú àjọ àgbáyé gbogbo ni ìgbà àti àkókò tó bá tó kí irú ìṣépọ̀ bẹ́ẹ̀ wáyé. Kí wọ́n ri pé ìtẹ̀síwájú bá ìmọ̀ Sáyẹ́nsì gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà nínú kókó-àdéhùn yi.

ẹ. Lákòótán, kí wọ́n ri pé wọ́n ń fi ohun gbogbo tó ń lọ tó Akọ̀wé-Gbogboògbò létí. Bíi Ọ̀rọ̀ tí ó ní ṣe pẹ̀lú ètò ààbò, àgbéyẹ̀wò òfin, ìsàkóso orílẹ̀-èdè, ètò ọrọ̀-ajé, àwùjọ àti ètò-ẹ̀kọ́ agbègbè bẹ́ẹ̀. Gbogbo ẹ̀ ló ní ọgbọ́n

àti ètò tí a fi ń gbé wọn kalẹ̀. Ọmọ-ẹgbẹ́ tí ó ń ṣe àkóso orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ gbọdọ̀ mọ̀ pé ìkáwọ́ àwọn l'àwọn ètò ìṣàkóso àwọn nǹkan wọ̀nyen wà, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà ní orí kejìlá àti ìkẹtàlá.

### *Kókó-àdéhùn 74*

Ọmọ ẹgbẹ́ àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè f'ẹnukò sí pé ìlànà tí wọ́n là kalẹ̀ látàrí àwọn orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ori yìí ṣe gbé e kalẹ̀ gbọdọ̀ wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn orílẹ̀-èdè ńlánlá tí ó yí i ká; nípa ìgbépọ̀ àlááfíà àti ìbójútó àyíká, ọrọ̀-ajé àti ètò-káràkátà lágbàáyé.

# Orí Kejìlá

## *Ètò níní Igi-Lẹ́yìn-Ọgbà Lágbàáyé*

### Kókó-àdéhùn 75

Àjọ àpapọ̀ yóò dá ètò igi-lẹ́yìn-ọgbà fún ètò ìṣàkóso àti àbójútó àwọn orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ sílẹ̀, ti yóò sì wà lábẹ́ àṣẹ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi àdéhùn tí ó bá tẹ̀nìkọ̀ọ̀kan mu.Lẹ́yìnàátò náà ni wọn ó máa pe orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ ni orílẹ̀-èdè tí wọ́n ń ṣíji bò.

### *Kókó-àdéhùn 76*

Àwọn kókó èròǹgbà ìgbékalẹ̀ ètò igilẹ́yìnọgbà gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà ni ìbámu pẹ̀lú ìdí ti Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè fi lélẹ̀ ni kókó-àdéhùn kìíní tí ó wà nínú àdéhùn yí. Àwọn ni ìwọ̀nyí:

a. Kí ìbàlẹ̀-ọkàn àti ààbò kárí-ayé pọ̀ si

b. Láti ri pé ìtẹ̀síwájú ń bá ètò ìṣèlú; ọrọ̀-ajé àwùjọ. àti ètò-ẹ̀kọ́, àwọn tí ó ń gbé ìlú tí a ń ṣegilẹ́yìn-ọgbà fún. Kí a sì ri pé ètò bí wọn ó ṣe lè máa dá ìjọba ara wọn ṣe tàbí kí wọn di ìlú Olómìnira ní ìbámu pẹ̀lú orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ si leè sọ ẹ̀dùn-ọkàn wọn ni ìbámu pẹ̀lú àdéhùn tàbí ìpinnu bí orílẹ̀-èdè ọ̀hún ṣe lẹ̀ bá àjọ igi-léyìn-ọgbà wọn ṣe pọ̀.

d Kí a sapá ri pe ìbọ̀wọ̀fún ètọ̀ àti òmìnira ẹ̀dá láì si pé a ń ya abo tàbí akọ sọ́tọ̀ wà. Àìkò si gbọdọ̀ ṣe ìyapa látàrí èdè, tàbí ẹ̀sìn. Kí a sí ri pe òmìnira ẹ̀dá kárí-ayé jẹ́ ohun ti àjọ náà gbọdọ̀ gbé láruge, àti pẹ̀lú

e Kí dọ́gbandọ́gba ìbọ̀wọ̀fún ara ẹni wà nínú bí a ṣe ń bá ara wa lò l'áwùjọ, ètò ọrọ̀-ajé, àti ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́ okòòwò láàrín gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ àgbáyé àti àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè wọn pátá. Ètò ìdájọ́ gbọdọ̀ wà níwọ̀ntúnwọ̀nsì fún àwọn ọmọ orílẹ̀-èdè tí a sọ náà láì sí ìtẹ̀mọ́bẹ̀lẹ̀kun tàbí ẹ̀hónú nípa ìdí-abájọ àti kókó tí ó wà nínú kókó-àdéhùn 80 níwájú.

## Kókó-àdéhùn 77

1. Àwọn orílẹ̀-èdè tí ìyà ń jẹ, tí wọ́n si ń fẹ́ ààbò wọ̀nyí; ti ètò ìṣegiléyìn-ọgbà náà yẹ gbọdọ̀ bá àjọ ètò ìṣegiléyìn-ọgbà pinnu. Irú àwọn orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ gbọdọ̀ jẹ́:

   a. Orílẹ̀-èdè tí ó wà lábẹ́ òfin;

   b Orílẹ̀-èdè tí wọ́n lè já kúrò l'ára orílẹ̀-èdè tí ó gbógun tì wọ́n l'átàrí ògun-àgbáyé kejì àti pẹ̀lù.

   d Orílẹ̀-èdè tí wọ́n finúfẹ́dọ̀ fi ara wọn sábẹ́ lẹ́tọ́ àṣẹ ìjọba orílẹ̀-èdè tí ó ń ṣàkoso orílẹ̀-èdè wọn.

2. Ìpinnu gbọdọ̀ wà lórí irú àwọn orílẹ̀-èdè tí a ti kà sílẹ̀ yen, kí wọ́n tó wà l'ábẹ́ ìṣàkóso àjọ tó ń ṣe igiléyìn-ọgbà náà.

## Kókó-àdéhùn 78

Orílẹ̀-èdè tí ó bá ti jẹ́ ọ̀kan l'ára ọmọ ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè kòlè pẹ̀lú orílẹ̀-èdè tí ó lẹ̀ ké gbàjàrẹ̀ lọ bá àjọ tó ń ṣegiléyìn-ọgbà fun àwọn orílẹ̀-èdè tí ìyà ń jẹ. Ìbáṣepọ̀ ààrín orílẹ̀-èdè ti ó jẹ́ ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ gbọdọ̀ jẹ́ èyí tí kálukú wọ́n gbọdọ̀ bọ̀wọ̀ fún ara; gẹ́gẹ́ bíi orílẹ̀-èdè tí ó ń dá àkóso ara rẹ̀ ṣe.

## Kókó-àdéhùn 79

Ìpinnu lórí ìṣegiléyìn-ọgbà fún orílẹ̀-èdè ti ìyà bá ń jẹ gbodọ̀ jẹ èyí ti àjọ tó ń ṣegiléyìnọgbà náà f'ọwọ́ sí. Bí àtúnṣe bá wà, ó gbọdọ̀ jẹ ìmọ̀ orílẹ̀-èdè tí àbòjútó náà kàn. Kọ́dà àṣẹ tí ó wà fún orílẹ̀-èdè tí ó jẹ́ ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ Àpapọ̀ orílẹ̀-èdè; gbọdọ̀ jẹ́ nǹkan ìfọwọ́sí gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ bí ó ṣe wà nínú kókó-àdéhùn 83 àti 85.

## Kókó-àdéhùn 80

1. Àyàfi bí ìpinu bá wà láàrín ọmọ-ẹgbẹ́ kọ̀ọ̀kan gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà nínú kókó-àdéhùn 77,79, àti 81; èyí tí ó fi orílẹ̀-èdè sábẹ́ àmojútọ́. Bí irú ìpinnu bẹ́ẹ̀ ò bá sí, kò sí nǹkan náà

lábẹ́ orí yìí tí ó lè f'ojú kéré ètò orílẹ̀-èdè kankan tàbí àwọn èèyàn tàbí ohun tí ó so orílẹ̀-èdè àgbáyé pọ̀ lábẹ́ àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè.

2. A ò gbọdọ̀ ri ìpínfọ̀ kìíní gẹ́gẹ́ bí ète láti dá ìjíròrò dúró tàbí láti sún un síwájú. Bẹ́ẹ̀ ni kí ì ṣe láti fa ọwọ́ aago ìpinnu àdéhùn láti ri pé àwọn orílẹ̀-èdè tó bá yẹ sabẹ́ ààbò bí ó ṣe wà ni kókó-àdéhùn 77 sẹ́yìn.

### *Kókó-àdéhùn 81*

Ìpinnu ètò ìṣegiléyìn-ọgbà gbọdọ̀ ṣe àfikún bí wọn ó ṣe máa ṣe àkóso orílẹ̀-èdè tí wọ́n ń dáàbò bò náà. kí wọ́n sì yan àwọn tí yóò máa bójútó àkóso ìjọba irú orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀. Ìjọ apàṣẹ bẹ́ẹ̀ la ó máa pè ní Ìjọ apàṣẹ àkóso. Ó lè jẹ́ yálà orílẹ̀-èdè kan tàbí jù bẹ́ẹ̀. Ó sì lè jẹ́ Àjọ Gbogboògbò alára pàápàá.

### *Kókó-àdéhùn 82*

Láì sí ìkùnsínú nípa ìpinnu tàbí àdéhùn tí ó wà ní kókó-àdéhùn 43, a lè yan agbègbè tàbí àwọn agbègbè tó ṣeé lò fún ààbò, tí yóò jẹ́ lára agbègbè ti ìpinnu náà pàṣe pé kí wọ́n máa ṣaláàbò wọn.

### *Kókó-àdéhùn 83*

1. Àjọ alábòójútó ni yóò máa ṣàkóso gbogbo ojúṣe Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè l'áwọn agbègbè tó ṣeé lò fún ààbò, àti ìfọwọ́sí òfin tí ó rí sí ìṣààbò àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n ń ṣegiléyìn-ọgbà fún pẹ̀lú.

2. Kókó èròǹgbà àjọ náà tí ó wà nínú kókó-àdéhùn 76 kò yọ àwọn èèyàn agbègbè tó ṣeé lo fún ìdáàbò náà sílẹ̀.

3. Àjọ alábòójútó gbọdọ̀ tẹ́wọ́ gba ìpinnu àti àdéhùn tí àjọ igiléyìn-ọgbà ṣe fún àwọn orílẹ̀-èdè ti ìyà ń jẹ bá ṣe ni láì sí ìkùnsínú kankan. Nípa bẹ́ẹ̀; àwọn ojúṣe Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà lábẹ́ ètò ìṣegiléyìn-ọgbà tí ó jẹ mọ́

ètò ìṣèlú ọrọ̀-ajé, àwùjọ àti ẹ̀kọ́ l'áwọn agbègbè tí ó ṣeé lò fún ààbò: yóò fẹsẹ̀ múlẹ̀ daada.

### *Kókó-àdéhùn 84*

Iṣẹ́ àjọ alákòóso ni láti rí pé àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n ń dáàbò bò ń sapá tiwọn náà ri pé ìbàlẹ̀-ọkàn àti ààbò wà kárí-ayé. Láti lè jẹ́ kí èyí ṣeéṣe, àjọ alákòóso náà máa yàn lára àwọn orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀: láti wa ṣiṣẹ́ àtinúwá kí ìbàlẹ̀-ọkàn lè wà; kárí-ayé àti ní agbègbè wọ́n pẹ̀lú.

### *Kókó-àdéhùn 85*

1. Ìpàdé Gbogboògbó ló lè pàṣẹ l órí ojúṣe Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè nípa ètò ìdáàbò bo àwọn orílẹ̀-èdè tí ó ń fẹ́ ìrànwọ́ láti lè jẹ́ kí wọ́n jẹ ànfàní ààbò tí wọ́n ti ṣe ìpinnu lé tàbí ṣe àtúnṣe sí.
2. Àjọ tí ó ń ṣegiléyìn-ọgbà fún àwọn orílẹ̀-èdè tí ó ń fẹ́ ìrànwọ́, tí wọ́n wà lábẹ́ àṣẹ Ìpàdé Gbogboògbò gbọdọ̀ ṣe ìrànwọ́ fún ìpàdé Gbogboògbò láti rí pé ó ṣe àwọn ojúṣe wọ̀nyí.

# Orí Kẹtàlá

## *Àjọ tí ó ń Ṣegilẹ́yìn-ọgbà*

### Ààtò

### *Kókó-àdéhùn 86*

1. Àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ Orílẹ̀-èdè wọ̀nyí ni wọn ó wà nínú Àjọ tí ó ń ṣegilẹ́yìn-ọgbà

   a. Àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ tí wọ́n ń ṣàkóso àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n ń segiléyìn-ọgbà fún.

   b. Irú àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ tí a ti sọ lábẹ́ kókó-àdéhùn 23 tí wọ́n ò sí nínú ọmọ-ẹgbẹ́ tí ó ń ṣegilẹ́yìn-ọgbà àwọn orílẹ̀-ede tí wọ́n saláàbò fún. Àti pẹ̀lù:

   d. Gẹ́gẹ́ bí ọmọ-ẹgbẹ́ mìíràn ti ìpàdé Gbogboògbò bá dìbò yàn fún ọdún mẹ́ta bá ṣe pọ̀ tó lọ́ lè wà nínú Àjọ tí n ṣegilẹ́yìn-ọgbà náà, èyíini bí o bá pọn dandan. Èyí ni láti ri pé iye àwọn-ẹgbẹ́ tó ṣaláàbò wà ni dọ́gbadọ́gba pẹ̀lú ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè tó ń ṣàkóso orílẹ̀-èdè tí wọ́n ń ṣaláàbò pẹ̀lú àwọ́n tí kì í ṣe ọmọ-ẹgbẹ́.

2. Ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ tó ń ṣegilẹ́yìnọgbà kọ̀ọ̀kan gbọdọ̀ yan aṣojú tó kún ojú-ìwọ̀n daadaa láti wa ṣojú ẹ̀ níbẹ̀.

### Ojúṣe àti Agbára

### *Kókó-àdéhùn 87*

Bí Ìpàdé Gbogboògbò àti àjọ aṣegilẹ́yìn-ọgbà tó wà lábẹ́ àṣẹ ẹ nínú ojúṣe wọn lè ṣe àwọn nǹkan wọ̀nyí:

a. Ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbájáde ìpàdé àjọ tó ń ṣe àkọ́so

b. Gbígba ìwé-ẹ̀họ́nú kí wọ́n si ṣ'àyẹ̀wò wọn pẹ̀lú àjọ tó ń ṣè àkọ́so.

d. Kí wọ́n fẹ́nukò si ìgbà kan pàtó pẹ̀lú àjọ tó ń ṣàkóso, àsìkò tí wọ́n ó máa ṣàbẹ̀wò si àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n ń ṣalàábò fún lóòrèkóòrè; àti pẹ̀lú

e. Kí wọ́n sì máa ṣe àwọn ojúṣe wọ̀nyí ní ìbámu pẹ̀lú òfin tí wọ́n kọ sílẹ̀ fí àjọ alábòójútó ń tẹ̀lé.

*Kókó-àdéhùn 88*

Àjọ aṣegilẹ́yìn-ọgbà náà yóò kó àwọn ìbéèrè jọ l'órí èto ìṣèlú, ọrọ̀-ajé, àwùjo, àti ìtẹ̀síwájú ètò-ẹ̀kọ́ láàrín àwọn olùgbé tó ń gbé orílẹ̀-èdè tí wọ́n ń ṣalábò fún. Bẹ́ẹ̀ sì ni àjọ tó ń ṣe àkóso orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ́ gbọdọ̀ tẹ̀lé ìlànà ìgbékalẹ̀ àwọn ìbéèrè náà nípa ìjábọ̀ fún ìpàdé Gbogboògbò.

**Ìdìbò**

*Kókó-àdéhùn 89*

1. Àjọ tó ṣààbò máa ṣe òfin ti yóò máa lo àti ọ̀nà ti yóò máa gbà yan Ààrẹ rẹ̀.

2. Àjọ tó ń ṣààbò náà yóò máa ṣe ìpàdé ni ìbámu pẹ̀lú òfin tí ó sọ pé bi ọ̀pọ̀ ọmọ-ẹgbẹ́ bá f'ẹnukò pé kí ìpàdé wáyé ni àjọ náà tó lè pe ìpàdé.

*Kókó-àdéhùn 91*

Àjọ tó ń ṣààbò gbọdọ̀ ri pé òun ṣe ìrànwọ́ nígbà tó bá ye, tó sì kàn wọ́n gbọ̀ngbọ̀n. Kí wọ́n ri pé Ètò ọrọ̀-ajé àti Àjọ tó ń bójútó àwùjọ àti àwọn àjọ tí wọ́n kàn dá sílẹ̀ káàkiri ń lọ déédé.

# Orí Kẹrìnlá

## Ilé-ẹjọ́ Ìdájọ́ Òdodo Àgbáyé

### Kókó-àdéhùn 92

Ìlé-ẹjọ́ ìdájọ́ òdodo àgbáyé ni yóò jẹ agbófinró fún Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè. Ilé-ẹjọ́ náà gbọdọ̀ máa ṣe ojúṣe rẹ̀ ní ìbámu pẹ̀lú òfin tí àwọn amòfin ti gbé kalẹ̀ èyí tí ó dá lé àgbékalẹ̀ òfin Ilé-ẹjọ́ ìdájọ́ òdodo ayéraye, kí ó sí jẹ́ abala kan pàtàkì nínú àdéhùn yí.

### Kókó-àdéhùn 93

1. Gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àgbáyé ni wọ́n gbọdọ̀ lẹ́nu nínú ìgbékalẹ̀ òfin Ilé-ẹjọ́ ìdájọ́ òdodo àgbáyé.
2. Orílẹ̀-èdè tí kì í ṣe ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè lè kópa nínú ìgbékalẹ̀ òfin Ilé-ẹjọ́ òdodo àgbáyé náà. Àmọ́ o, Ìpàdé gbogboògbò ló lè sọ ẹni tó lè kópa nínú àwọn orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀; nípa ohun tí Àjọ Aláàbò bá sọ.

### Kókó-àdéhùn 94

1. Ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè kọ̀ọ̀kan ni ó gbọdọ̀ jẹ́jẹ̀ẹ́ pé òun yóò faramọ́ ìpinnu Ilé-ẹjọ́ ìdájọ́ òdodo tí òun bá bá wọn ṣe ìpàdé tí wọ́n ti ṣe ìpinnu náà.
2. Bí ẹnìkan bá kùnà láti ṣe ojúṣe tí ẹ̀ gẹ́gẹ́ ọ̀ ìdájọ́ Ilé-ẹjọ́, ẹnìkejì lè lọ fi tó Àjọ alábòójútó létí. Àjọ alábòójútó sì lè yálà dábàá tàbí ṣe ìpinnu lórí ìgbésẹ̀ tó yẹ láti ri pé ìdájọ́ náà fẹsẹ̀ múlẹ̀.

### Kókó-àdéhùn 95

Kò sí ibìkankan nínú Àdéhùn yí tí ó lè dènà kí awọ̀n ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè máa gbé ìgbésẹ̀ tí ó lè jẹ́ kí wọ́n tètè rójútùú sí èdèàìyedè àárín wọn, nípa gbígbé ọ̀rọ̀ wọn síwájú

ikọ̀ olùṣèwádìí; gẹ́gẹ́ bí ìpinnu tó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ tàbí èyí tí yóò wà lọ́jọ́ iwájú.

***Kókó-àdéhùn 96***

1. Yálà Ìpàdé Gbogboògbò tàbí Àjọ alábòójútó lè bẹ Ilé-ẹjọ́ ìdájọ́ òdodo àgbáyé kí ó gbà àwọn ní ìmọ̀ràn lórí ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́ òfin.
2. Àwọn ẹ̀ka Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè kéréjekéréje mììràn àti àwọn àjọ kéékèèké tí a kanlẹ̀ dá sílẹ̀ lè gba àṣẹ láti ọ̀dọ̀ Ìpàdé Àpapọ̀, wọ́n sì lè gba ìmọ̀ràn ilé-ẹjọ́ lórí ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ̀ òfin, èyí tí kò kọjá àwọn akitiyan wọn.

# Orí Kẹẹ̀dógún

## *Olú Ilé-iṣẹ́*

### *Kókó-àdéhùn 97*

Olú Ilé-iṣẹ́ náà máa ní Akọ̀wé-Àgbà kan, kí ó si gba àwọn òṣìṣẹ́ tí Àjọ náà bá rò pé yóò wúlò pẹ̀lú. Ìpàdé Gbogboògbò ni yóò yan Akọ̀wé-Àgbà náà lẹ́yìn ti Àjọ alábòójútó bá ti fọwọ́wsíi, òun ni yóò jẹ́ ọ̀gá Alákòóso pátá ní àjọ náà.

### *Kókó-àdéhùn 98*

Iṣẹ́ ọ̀gá Alákòóso pátá ni Akọ̀wé-Àgbà náà gbọdọ̀ máa ṣe nínú yàlá gbogbo Ìpàdé Gbogboògbò tí ó bá wáyé, ti Àjọ Alábòójútó, tàbí ti Àjọ aṣaláàbò. Bẹ́ẹ̀ sì ni yóò máa ṣe iṣẹ́ ti àwọn ẹ̀ka yìí bá yàn án láti ṣe. Ọdọọdún ni Akọ̀wé-Àgbà yóò máa jábọ̀ l'órí iṣẹ́ ti àjọ náà ti gbé ṣe.

### *Kókó-àdéhùn 99*

Bí Akọ̀wé-Àgbà náà bá sàkíyèsí pé ọ̀rọ̀ kan lè fa àìbalẹ̀-ọkàn àti hílàhílo, ó lè fi tó Àjọ Alábòójútó létí.

### *Kókó-àdéhùn 100*

1. Akọ̀wé-Àgbà àti àwọn òṣìṣẹ́ yóòkù ò gbọdọ̀ béèrè tàbí gba àṣẹ láti ọ̀dọ̀ ìjọba kan tàbí alágbára mìíràn láti ìta yàtọ̀ sí Àjọ wọn. Wọ́n gbọdọ̀ ri pé wọn sára fún ìwà tí yóò ṣe àkóbá fún wọn gẹ́gẹ́ bíi òṣìṣẹ́ tí ó ṣiṣẹ́ fún àgbáyé.
2. Ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè gbọdọ̀ jẹ́jẹ̀ẹ́ pé àwọn yóò b'ọwọ̀ fún Akọ̀wé-Àgbà àti àwọn òṣìṣẹ́ ẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi òṣìṣẹ́ tó ń ṣiṣẹ́ fún àgbáyé, tí ẹnikẹ́ni ò sì gbọdọ̀ gbìyànjú láti dí wọn lọ́wọ́ lẹ́nu iṣẹ́ wọn

*Kókó-àdéhùn 101*

1. Gẹ́gẹ́ bí òfin tí Ìpàdé Gbogbòogbò ṣe, Akòwé-Àgbà nì yóò máa yan àwọn òṣìṣẹ́ àjọ náà.

2. Àwọn òṣìṣẹ́ tí ó kún ojú-ìwọ̀n ni wọ́n ó kòó sí àjọ ètò ọrọ̀-ajé àti àwùjọ, àjọ Aṣaláàbò gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà ni ẹ̀ka àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè. Ni Olú Ilé-iṣẹ́ ni àwọn òṣìṣẹ́ yìí yóò ti máa ṣiṣẹ́.

3. Ohun tí ó jẹ àjọ náà lógún ni pé kí ó ri pé àwọn òṣìṣẹ́ àwọn ń gbádùn; kí wọ́n ṣiṣẹ́ ti ó kúnjú ìwọ̀n. Ó sì gbọdọ̀ ri pé láti ibikíbi ni òun ti ń gba àwọn òṣìṣẹ́ káríayé.

# Orí Kẹrìndílogun

## *Ìpèsè Lọ́kan-ò-Jọ̀kan*

### *Kókó-àdéhùn 102*

1. Gbogbo ìpinnu àti àkọsílẹ̀ ẹgbẹ́ lágbàáyé ti èyíkèyíì nínú ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè bá ti fọwọ́sí l'éyìn àdéhùn yí ti di òfin àmúlo, tí wọn ó sì mú lọ si olú Ilé-iṣẹ́ fún títẹ̀ jáde.
2. Kò sí ẹniyòówù tí ó kópa nínú ṣíṣe àkọsílẹ̀ òfin tàbí ìpinnu tí kò ì f'orúkọ sílẹ̀ lẹ́gbẹ́ gẹ́gẹ́ bíi ìlànà tí ó wà ní ìpínfọ̀ kìíní àdéhùn yí tí ó lè tako àkọsílẹ̀ tàbi ìpinnu lọdọ̀ èyíkèyí lára àwọn àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè.

### *Kókó-àdéhùn 103*

Bí ó bá ṣẹlẹ̀ pé ìfagagbága ṣẹlẹ̀ l'áàrín ojúṣe àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè l'ábẹ́ àdéhùn yí àti ìpinnu àjọ àgbáyé; ojúṣe wọn nínú àdéhùn yí ni yóò lékè

### *Kókó-àdéhùn 104*

Àjọ náà yóò máa jẹ ànfàní ni ìbámu pẹ̀lú òfin ní agbègbè àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ rẹ̀ láti lè ṣe iṣẹ́ rẹ̀ láṣeyege.

### *Kókó-àdéhùn 105*

1. Àjọ náà yóò máa jànfàní, yóò si máa ri ààbò ní àgbegbe àwọn-ẹgbẹ́ ẹ láti lè jẹ́ kí ó ṣàṣeyọrí iṣẹ́.
2. Àwọn Aṣojú Ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ Orílẹ̀-èdè àti àwọn òṣìṣẹ́ àjọ náà yóò jànfàní àwọn ètò yí . Bẹ́ẹ̀ sì ni ààbò yóò wà fún wọn ní ìbámu pẹ̀lú ìbáṣepọ̀ wọn níyànà ọ̀tọ̀ pẹ̀lú Àjọ náà.
3. Akọ̀wé-Àgbà lè dábàá láti ri pé àwọn kókó tó wa nínú ìpínfọ̀ kìíní àti ìkejì kókó-àdéhùn yí yé àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ tàbi kí ó dàbàá ìpàdé fún àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè láti ri pé àdéhùn náà f'ẹsẹ̀ mulẹ̀.

# Orí Ketàdílógún

## *Ètò Alábòójútó Adelé*

### *Kókó-àdéhùn 106*

Títí dìgbà tí ìpinnu tí ó wà nínú kókó-àdéhùn 43 yóò fi dòfin, gégé bí èrò àjọ alábòójútó yóò ṣe máa ṣe àwọn ojúṣe rẹ̀ tí ó wà nínú kókó-àdéhùn 42. Iye àwọn orílẹ̀-èdè tó wà l'ára àwọn orílẹ̀-èdè Mẹ́rin tí wọ́n f'ọ́wọ́ síwèé ìpinnu ní Ìlú Moscow ní 30-10-1943, àti ni orílẹ̀-èdè Faranṣé, gẹ́gẹ́ bíi ìlànà tí ó wà ni ìpínfọ̀ karùn-ún nínú ìpinnu, náà, gbọdọ̀ f'ọ̀rọ̀ lọ ara wọn. Bẹ́ẹ̀ ni, wọ́n sì lè ṣe irú ìpinnu bẹ́ẹ̀ lásìkò ti ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó lè fa àìbalẹ̀-ọkan bá wa lágbàáyé; láti lè jẹ́ ki ìbàlẹ̀-àyà àti àábò wà.

### *Kókó-àdéhùn 107*

Kò gbọdọ̀ sí ọ̀rọ̀ kan nínú àdéhùn yí tí yóò tàpá sí ìpinnu tí wọ́n ti ṣe nígbà ogun Àgbáyé Kejì l'óri orílẹ̀-èdè tí ó lòdì si èyíkéyìí nínú àwọn orílẹ̀-èdè tí ó f'ọwọ́ sí àdéhùn yi gẹ́gẹ́ bi yálà ìpinnu tàbí àṣẹ tí àwọn ìjọba ti wọ́n faramọ́ irú ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀.

# Orí Kejìdilógún

### *Àtúnṣe*

### *Kókó-àdéhùn 108*

Àjọmọ̀ ni àtúnṣe si àdéhùn yí yóò jẹ́ lẹ́yìn tí ìpàdé Gbogboògbò àwọn ọmọ-ẹgbẹ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè bá wáyé, ti ìkọ-méjì nínú idá mẹ́ta àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ náà bá ti dìbò faramọ́ àtúnṣe bẹ̀ẹ̀. Bẹ̀ẹ̀ ni wọ́n lè ṣe àtúnṣe nípa ìgbésẹ̀ yí bákan náà nípa ki ìkó-méjì nínú ìdá mẹ́ta ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ dìbò fi àpapọ̀ orílẹ̀-èdè ara mọ́ ọn, àti àwọm ọmọ-ẹgbẹ́ ayérayé tí ó wà nínú Àjọ alábòójútó.

### *Kókó-àdéhùn 109*

1. Ìkọ́-méjì nínú ìdá mẹ́ta àwọn ọmọ Ìpàdé àpapọ̀ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè tí wọ́n bá dìbò àti ìbò àwọn ọmọ àjọ alábòójútó mẹ́sàn-án lè gbé àdéhùn yí yẹ̀wò. Ìbò kan ni ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè gbọdọ̀ dì.

2. Àyípadà yòówù tí ó bá bá àdéhùn yí gẹ́gẹ́ bí ìkó-meji nínú ìdá mẹ́ta àwọn ti ó dìbò ìpàdé yóò di àmúlò bi ìkó-méjì nínú ìdá mẹ́ta àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè ti wón jẹ́ ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ alábòójútó ayérayé bá ti f'ọwọ́ sí i.

3. Bí irú ìpàdé bẹ̀ẹ̀ ò ba ì tíì wáyé kí ó tó di àsìkò ìpàdé gbogboògbò ọdọọdún ẹlẹ́ẹ̀kẹwàá títí tí àdéhùn náà fi di àmúlò, wọn ó fi àbá pé kí wọ́n pe ìpàdé bẹ̀ẹ̀ sínú ìlànà Ìpàdé Gbogboògbò.. Àti pé bí ọ̀pọ̀ ọmọ-ẹgbẹ́ Ìpàdé Gbogboògbò bá ti dìbò faramọ̀ ìpè, ti ọ̀kan lára àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ alábòójútó méje bá ti dìbò pé kí wọ́n pe ìpàdé, ó di dandan nì yẹn kí wọ́n pe ìpàdé náà.

# Orí Kọkàndílógún

## Ìfàṣẹlé àti Ìfọwọ́sí

### Kókó-àdéhùn 110

1. Àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n láṣẹ ìfọwọ́sí àkosílẹ̀ ni yóò fàṣẹ lé àdéhùn yí ní ìbámu àti ìlànà pẹ̀lú òfin ìṣàkóso orílẹ̀-èdè wọn.

2. Ìjọba Àpapọ̀ orílẹ̀-èdè Àmẹ́ríkà ni wọ́n ó gbée ìfàṣẹlé ná lò bá. Àmẹ́ríkà ni yóò ṣẹ̀ṣẹ̀ wá fi tó àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n láṣẹ ìfọwọ́sí àkọsílẹ̀ àti Akọ̀wé-Àgbà àjọ náà bí wọ́n bá ti yǎn án.

3. Bí àwọn orílẹ̀-èdè wònyí: Orílẹ̀-èdè Olómìnira China, ilẹ̀ Faransé, Àjọ orílẹ̀-èdè Olómìnira Ìfaradẹ̀lú, Àpapọ̀ Orílẹ̀-èdè Gẹ̀ẹ́sì àti Ireland àti Àpapọ̀ orílẹ̀-èdè Àmẹ́ríkà pẹ̀lú ọpọ yanturu àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n lásẹ Ìfọwọ́sí àkọsílẹ̀ bá gbé ìfàṣẹ lé àdéhùn yí kalẹ̀, ó di àmúlo bíi òfin nìyẹn. Ìjọba àpapọ̀ orílẹ̀-èdè Àmẹ́ríkà ni yóò ṣààtò bi ìfàṣẹlẹ́ náà yóò ṣe di títẹ̀, ti yóò sì pín in kárí àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n ní àṣẹ ìfọwọ́sí náà.

4. Láti ọjọ́ tí wọ́n bá ti gbé ìfàṣelé àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n láṣe ìfọwọ́sí àdéhùn náà kalẹ̀, tí ó sì ti d'òfin ni àwọn orílẹ̀-èdè di ìpìlẹ̀ Ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè.

### Kókó-àdéhùn 111

Ìjọba àpapọ̀ àwọn orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ni yóò tọ́jú àdéhùn yi. Ìtẹ̀jáde àwọn èèyàn orílẹ̀-èdè China, Ilẹ̀ Faranṣẹ́, Rọ́síà, Gẹ̀ẹ́sì àti àwọn ará Sípéènì náà fẹsẹ̀ múlẹ̀ bíi àdéhùn yìí náà ni. Ìjọba orílẹ̀-èdè Àmẹ́ríkà ni yóò máa pin ẹ̀dà àdéhùn náà ti wón ti fọwọ́si sí àwọn ìjọba orílẹ̀-èdè ti wón fọwọ́sí àdéhùn náà.pe Ìgba-ara-ẹni-gbọ̀ ni àwọn asọjú àwọn ìjọba Àjọ àpapọ̀ orílè- èdè fi fọwọ́sí àdéhùn yí.

# Àmúlò Òfin Ilé-Ẹjọ́ Ìdájọ́ Òdodo Àgbáyé

## *Kókó-àdéhùn 1*

Àdéhùn tí ó wáyé láàrín Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè ló dá ilé ìdájọ́ òdodo àgbáyé sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀ka tí yóò máa gbé òfin ró àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè; ní ìbámu pẹ̀lú ìpèsè àmúlò òfin yìí.

# Orí Kìíní

## *Ààtò ilé-ẹjọ́ náà*

### *Kókó-àdéhùn 2*

Àwọn adájọ́ àgbà ti wọ́n jẹ́ ọmọlúàbí, ti wọ́n kúnjú ìwọ̀n l'óríl̀ẹ̀-èdè wọn, tí wọ́n bá ti dìbòyàn láì fi ọ̀mọ̀ orílẹ̀-èdè tí wọ́n jẹ́ ṣe ni yóò máa ṣàkóso ilé-ẹjọ́ náà. Wọ́n sì lè jẹ àgbà amòfin tó jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ àgbáyé ni wọ́n pẹ̀lú.

### *Kókó-àdéhùn 3*

1. Àwọn mẹ́ẹ̀dógún ni wọn yóò jẹ́ ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-ẹjọ́ náà, àmọ́, ọmọ-ẹgbẹ́ méjì ò gbọdọ̀ ti orílẹ̀-èdè kan náà wá.
2. Bí èèyàn bá tan mọ́ orílẹ̀ púpọ̀, tí ó sì fẹ́ jẹ́ ọ̀kan l'ára ọmọ-ẹgbẹ́, Ilé-ẹjọ́ náà ó lè dà á, ó kàn jẹ́ pé orílẹ̀-èdè tí ó bá ń ṣètò ẹ ni won o mọ̀ ọn mọ́ ni

### *Kókó-àdéhùn 4*

1. Ni Ìpàdé Gbogbogbò ni wọ́n ó tí yàn àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-ẹjọ́ náà. Àwọn Àjọ alábòójútó ni yóò yàn wọ́n láti inú ìwé ti àwọn ti ẹgbẹ́ lágbàáyé ni Ilé-ẹjọ́ ayérayé ti ó ńrí sí àtúntò, ni ìbámu pẹ̀lú àwọn ìpèsè tí ó wà nísàlẹ̀ wọ̀nyí.
2. Bí ó bá ṣẹlẹ̀ pé kò sí aṣojú ọmọ-ẹgbẹ́ àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè nínú Ilé-ẹjọ́ ayérayé tí ó ń rí sí àtúntò, àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ láti orílẹ̀-èdè gbogbo tí Ìjọba wọn yàn yóò yan aṣojú fún ìdí yìí, gẹ́gẹ́ bíi ìlànà tí ó wà nínú kókó-àdéhùn 44 ti ó wáyé ni ìpàdé tí wọ́n ṣe ni Ìlú Hague ni 1907 fún Ìpaná èdèàìyédè tó ń lọ lágbàáyé nígbà náà lọ́gán.
3. Ọ̀ná ti orílẹ̀-èdè tí ó wà lára àwọn tí ó fọwọ́sí òfin yìí àmọ́ tí kì í ṣe ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè fi lè kópa nínú ètò ìdìbò-yan ọmọ-ẹgbẹ́ sí ilé-ẹjọ́, tí kò sì sí àkànṣe ìpinnu kan pàtó ti Ìpàdé Gbogbogbò fi lélẹ̀ gẹ́gẹ́ bíi àbá ti Àjọ alábòójútó ṣe.

### *Kókó-àdéhùn 5*

1. Akọ̀wé-Àgbà Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè gbọdọ̀ ti fi ìwé ṣọwọ́ sí àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-ẹjọ́ tí ó n ṣàtúnṣe láti bíi oṣù mẹ́ta sáájú, àti sí àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ orílẹ̀-èdè tí wọ́n yàn nínú kókó-àdéhùn 4, ìpínfọ̀ kejì, ti Akọ̀wé-Àgbà náà ó sì fi tó wọn létí pé wọn ó yan àwọn ti yóò gbàṣẹ bí ọ̀mọ-ẹgbẹ́ Ilé-ẹjọ́ náà.

2. Ẹgbẹ́ kankan kò lè yàn ju èèyàn mẹ́rin lọ; ó pọ̀ tán, ti méjì nínú wọn lè jẹ́ ọmọ orílẹ̀-èdè wọn. Ẹgbẹ́ kan kò gbọdọ̀ yan aṣojú ti yóò pọ níye ju ààyè tó wa láti dìbò yan èèyàn sí lọ.

### *Kókó-àdéhùn 6*

Ẹgbẹ́ kọ̀ọ̀kan gbọ́dọ̀ fi tó Ile-ẹjọ́ tó ga jù lọ l'órílẹ̀-èdè rẹ̀, ẹ̀ka tí ó ń rí sí ètò òfin, àti Ilé-ìwé amòfin àti pẹ̀lú àwọn akadá ti o gbajúmọ́ ètò òfin àgbáyé létí kí wọ́n tó dábàá yan aṣojú náà.

### *Kókó-àdéhùn 7*

1. Akọ̀wé-Àgbà yóò tẹ orúkọ àwọn tí wọ́n yàn náà ni ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé jáde. Yàtọ̀ sí ohun tí ó wà nínú kókó-àdéhùn 12, ìpínfọ̀ 2, àwọn tí orúkọ wọn bá ti yọ nínú ìwé náà ni ó tẹ̀wọ́n gẹ́gẹ́ bíi ọmọ-ẹgbẹ́.

2. Akòwé-Àgbà yóò gbé ìwé tí orúkọ náà wá han ìpàdé Gbogboògbò àti Àjọ alábòójútó fún àyẹ̀wò.

### *Kókó-àdéhùn 8*

Ìpàdé Gbogboògbò àti Àjọ alábòójútó yóò yan àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-ẹjọ́ náà lọ́tọ̀ọ̀tọ̀, láì jẹ́ kí ọwọ́ keji mọ̀.

### *Kókó-àdéhùn 9*

Àwọn ònídìbò gbọdọ̀ máa ní i lọ́kàn ní gbogbo ètò ìdìbò pé ẹni ti àwọn yóò yàn gbọdọ̀ kún ojú-òsùnwọ̀n tó yẹ. Bákan náà, àjọ ọ̀hún lápapọ̀ gbọdọ̀ mọ̀ pé ìlànà tó bójúmu lọ́nà òfin lòun tẹ̀lé.

### *Kókó-àdéhùn 10*

1. Àwọn ti wọ́n bá ti ní ìbò tí ó pọ̀ jù nínú ìbò tí wọ́n dì ni Ìpàdé Gbogboògbò àti ti Àjọ Alábòójútó ló yege nínú ètò ìdìbòyàn náà.

2. Ìbò-kíbò tí Àjọ Alábòójútó bá dì, yálà ìbò láti yan àwọn amòfin àgbà ni ò; tàbí fún yíyan àwọm ọmọ-egbẹ́ ìpàdé ńlá tí a lérò ni kókó-àdéhùn 12, gbọdọ̀ wáyé láàrín gbogbo ọmọ-ẹgbé ni; yálà ó jẹ́ ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ alábòójútó ayérayé tàbí ọmọ-ẹgbẹ́ aláfarahẹ́.

3. Bi ó bá ṣẹlẹ̀ pe bí ọmọ orílẹ̀-èdè kan tó gbe àpótí ìbò bá ju ọ̀kan lọ, tí ó jẹ́ pé ìbò àwọn méjèèjì ló pọ̀ jù nínú ìbò Ìpàdé Gbogboògbò àti ti Àjọ Alábòójútó, èyí ti ó dàgbà ninú àwọn tí wọ́n dìbò fún náà ni wọn ó gbà wọlé.

### *Kókó-àdéhùn 11*

Bi aaye kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ bá ṣi sílẹ̀ l'ẹ́yìn ti wọ́n bá ti pàdé dìbò lẹ́ẹ̀kínní, wọn gbodọ̀ pe ìpàdé ẹlẹ́ẹ̀keji, tàbí ẹlẹ́ẹ̀kẹta láti dí ààyè tó ṣófo náà.

### *Kókó-àdéhùn 12*

1. Lẹ́yìn ìdìbòyàn ẹlẹ́ẹ̀kẹta, síbẹ̀ ti ààfo kan sì tún ṣi sílẹ̀, wọn ó wà pe ìpàdé àjùmọ̀ṣe ẹlẹ́ni mẹ́fà èyi ti ó jẹ́ pe Ìpàdè

Gbogboògbò yóò fa èèyàn mẹ́ta kalẹ̀, Àjọ Alábòójútó náà yóò fa ẹni mẹ́ta kalẹ̀. Ìgbàkígbà ni yálà Ìpàdé Gbogboògbò tàbí Àjọ Alábòójútó lè pe ìpè kí àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ wá dìbòyan ẹnìkan sáàyè kan tó bá ṣì ṣófo. Ó sì gbọ́dọ̀ jẹ àtẹ́wọ́gbà ọmọ ẹgbẹ́ àjọ méjèèjì.

2. Bí orúkọ èèyàn ò tiẹ̀ si nínú ètò ìyànnìyàn bí ó ṣe wà nínú kókó-àdéhùn 7 ìpàdé àwọn ẹgbẹ́ méjèèjì lẹ̀ fẹnukò yàn án bí ó bá ti kún ojú-ìwọ̀n irú ẹni tẹ́gbẹ́ méjèèjì ń fẹ́.

3. Ní àpapọ̀ àwọn ẹgbẹ́ méjèèjì bá ri pé àwọn ṣẹ̀sẹ̀yọrí nínú ètò ìdìbòyan ẹnìkan náà, àwọn òṣìṣẹ́ Ilé-ẹjọ́ tí wọ́n ti dìbò yan ni wọn ó jùmọ̀ fẹnukò si ìgbà tí wọn ó ṣètò ìdìbòyan s'áàyè tó ṣófo náà láàrín àwọn tí wọ́n ti dìbò fún tẹ́lẹ̀ yálà nínú Ìpàdé Gbogboògbò tàbí Ìpàdé Àjọ Alábòójútó.

4. Bí ìbò àwọn adájọ́ àgbà náà bá jẹ́ ọgbọọgba, adájọ́ àgbà tó dàgbà jù ni yóò dìbò kan yanjú ẹ.

***Kókó-àdéhùn 13***

1. Ọdún mẹ́sàn-án ni àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ ilé-ẹjọ́ yóò fi ṣ'iṣẹ́ wọn; àmọ́ ò, wọ́n lè tún wọn yàn padà sípò l'ẹ́yìn ọdún mẹ́sàn-àn yìí. Àtúnyàn bẹ́ẹ̀ lè wáyé bí àwọn adájọ́ àgbà tí wọ́n dìbò yàn lakọ̀kọ́ bá ti fẹ́rẹ̀ lo àkókò wọn bùṣe. Bi àsìkò márùn-ún nínú wọn bá ti fẹ́rẹ̀ parí ni òpin ọdún kẹta ti àkòkó adájọ́ àgbà márùn-ún mìíràn yóò tún parí lópin ọdún kẹfà, ètò ìdìbò bẹ́ẹ̀ tún lè wáyé.

2. Akọ̀wé-Àgbà ni yóò ṣe ètò bí wọ́n ò ṣe yan àwọn adájọ́ àgbà ti àsìkò wọn bá ti dópin gẹgẹ bí à ṣe sọ ní ìpín kẹta àti ìkẹfà lẹ́sẹ kẹfà, bí wọ́n bá ti parí ètò ìdìbò àkọ́kọ́.

3. Àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-ẹjọ́ ni yóò máa ṣe ojúṣe àwọn adájọ́ ti ààyè wọn bá ṣófo títí wọn ó fi yan àwọn ẹlòmíràn dípò.

Àmọ́ bí àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-ẹjọ́ náà bá ń ṣẹjọ́ kan l'ọ́wọ́, tí wọ́n fi yàn adájọ́ àgbà s'àáyè tó ṣófo náà, kò ni dá ẹjọ́ náà dúró torí bẹ́ẹ̀. Ó gbọdọ̀ parí ẹ̀ ni, kí wọ́n tó fàáyè náà sílẹ̀.

4. Bí ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-ẹjọ́ ba fẹ fìwé sílẹ̀ pe òun kò ṣiṣẹ́ mọ́; Ààrẹ Ilé-ẹjọ́ náà ni yóò fìwé náà ṣ'ọwọ́ si. Òun ni yóò sẹ̀ṣẹ̀ wà fi ṣ'ọwọ́ sí Akọ̀wé-Àgbà. Látìgbà tí ó bá ti détìígbọ̀ Akọ̀wé làáyè kan ti sí sílẹ̀.

## *Kókó-àdéhùn 14*

Ọ̀na kan náà ti wọ́n ti là kalẹ̀ náà ni wọn ó gbà fi dì àáfò tó bá wà bí ó ṣe ń ni ìbò alàkọ́ọ́kó. Àmọ́ àwọn nǹkan wònyí gbọdọ̀ ṣẹlẹ̀: Akọ̀wé-Àgbà gbọdọ̀ fiwé-ìpè síta l'áàrín oṣù kan ti àáfò náà bá ti ṣí sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà nínú àdéhùn 5. Bẹ́ẹ̀ sì ni Àjọ Alábòójútó ni yoò dájọ́ ti wọn ó dìbò míìràn yan èèyàn s 'áàyè náà.

## *Kókó-àdéhùn 15*

Bi wón bá yan ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-ẹjọ́ láti rọ́pò ọmọ-ẹgbẹ́ ti àsìkò rẹ̀ kò ì parí, ìba àkókò tó kù kí ó parí àsìkò rẹ̀ ni ẹni ti wọn yàn náà yóò lò níbẹ̀.

## *Kókó - àdéhùn 16*

1. Ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-ẹjọ́ kankan kò gbọdọ̀ kópa nínú ètò ìṣèlú tàbí àkóso kankan tàbí ìṣẹ́ tí ó lè gba àkókò rẹ̀.

2. Bi ìrùjú bá wà lórí kókó yìí, Ilé-ẹjọ́ ni yóò yanjú ẹ̀.

## *Kókó-àdéhùn 17*

1. Ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-Ẹjọ́ kankan kò gbọdọ̀ gbẹ́jọ́ rò fún èèyàn.

2. Kò sì ọmọ-ẹgbẹ́ tí ó gbọdọ̀ kópa nínú ẹjọ́ tí wọ́n bá gbé wá síwájú Ilé-ẹjọ́ náà tí ó bá ti fìgbà kan jẹ agbẹjọ́rò òkan l'ára

àwọn ti ọrọ̀ náà kàn tẹ́lẹ̀, tàbí kí ó jẹ́ ọ̀kan lára ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-ẹjọ́ ni orílẹ̀-èdè rẹ̀ tàbí ti àgbáyé; tàbí kí ó ti fìgbà kan jẹ́ ọ̀gá tí ó ń ṣe ìwádìí lórí ẹjọ́ náà ri.

3. Bi ìrújú bá wà lórí kókó yìí, Ilé-ẹjọ ni yóò yanjú'ẹ.

## *Kókó-àdéhùn 18*

1. Láì jẹ́ pé ìpinnu àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ tó kù, kò sí ẹni tó lè lé ọmọ-ẹgbẹ́ ilé-ẹjọ́ kankan. Bí wọ́n bá rí i pé kò lè ṣe ṣ'ojúṣe rẹ̀ mọ́ ni wọ́n tó lè panupọ̀ lé irú ọmọ-ẹgbẹ́ bẹ́ẹ̀.

2. Régísírà ni yóò fi tó Akọ̀wé-Àgbà léti bí ẹgbẹ́ bá pinnu láti lé ẹnikan l'ára wọn lọ.

3. Bí Régísírà bá ti fi tó Akọ̀wé-Àgbà létí; a jẹ́ pé ààyè onítọ̀hún ṣòfo niyẹn.

## *Kókó-àdéhùn 19*

Ààbò tó péye kárí-ayé gbọdọ̀ wà fún ọmọ-ẹgbẹ́ ilé-ẹjọ́ náà tí ó sin ṣiṣẹ́ níbẹ̀

## *Kókó-àdéhùn 20*

Wọn ó kọ́kọ́ ṣe ìbúra fún ọmọ-ẹgbẹ́ kọ̀ọ̀kan tí yóò sì jẹ́jẹ̀ẹ́ pé òun yóò ṣe iṣẹ́ òun tọkàn-tara kí ó tó bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ní ilé-ẹjọ́ náà.

## *Kókó-àdéhùn 21*

1. Ilé-Ẹjọ́ náà ni yóò yan Ààrẹ àti igbákejì Ààrẹ fún ọdún mẹ́ta fún ìgbà akọ́kọ́. Wọ́n lè dìbò tún wọn yàn sípò.

2. Ilé-Ẹjọ́ náà ni yóò yan Régísírà fún ara rẹ̀. Ó sì lè pèsè ààyè fún òṣìṣẹ́ tí ó bá rò pé ó yẹ níbẹ̀ bákan náà.

## *Kóko-àdéhùn 22*

Ìlú Hague ni Ilé-Ẹjọ́ náà yóò wà. Èyí kò sọ pé Ilé -Ẹjọ́ náà ò lè ṣiṣẹ́ níbikíbi bí Ilé-Ẹjọ́ náà bá ri pé ó pọn dandan fún un láti pa ìbùjòkóò náà dà.

2. Ibi tí Ilé-Ẹjọ́ náà wà ni Ààrẹ àti Régísírà yóò máa gbé.

## *Kóko-àdéhùn 23*

1. Gbogbo ìgbà ni Ilé-Ẹjọ́ náà gbọdọ̀ máa ṣiṣẹ́; àyàfi ìgbà ti Ilé-Ẹjọ́ náà bá wà ní ìsimi. Ilé-Ẹjọ́ náà ni yóò mu ìgbà kan ti yóò máa lò fún ìsinmi náà.

2. Gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-Ẹjọ́ náà ni ó lẹ́tọ̀ọ́ láti lọ fún ìsinmi. Àsìkò ti wọn ò máa lọ wà lọ́wọ́ bi orílẹ̀-èdè adájọ́ àgbà kọ̀ọ̀kan bá ṣe jìnà sí ìlú Hague tó. Ilé-Ẹjọ́ lo láse láti pinnu àkòkò ìsinmi náà fún àwọn ọmọ-ẹgbẹ́.

3. Láì jẹ́ pé ọmọ-ẹgbẹ́, wà lẹ́nu ìsinmi, àmódi tàbí ìdí mìíràn pàtàki tí ó sì ti sọ fún Ààrẹ tẹ́lẹ̀,kò si ọmọ-ẹgbẹ́ tó gbọdọ̀ pa ìpàdé Ilé-Ẹjọ́ kankan jẹ.

## *Kókó-àdéhùn 24*

1. Bí a bá rí ìdí kan pàtàkì ti ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-Ẹjọ́ náà ò fi ni dá si ìpinnu Ilé-Ẹjọ́, l'órí ọ̀rọ̀ kan pàtó, ó gbọ́dọ̀ fi tó Ààrẹ létí.

2. Bi Ààrẹ bá ri pé fun ìdí kan pàtàkì, ọmọ-ẹgbẹ Ilé-Ẹjọ́ náà kọ yẹ kí ó wà ni ìpàdé náà, yóò sọ fún irú ọmọ-ẹgbẹ́ bẹ́ẹ̀ kó má wàá.

3. Bí èdèàìyèdé bá wáyé l'áàrín àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-Ẹjọ́ àti Ààrẹ nipa irú ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀, Ilé-Ẹjọ́ ni yóò ṣe onílàjà wọn.

## *Kókó-àdéhùn 25*

1. Yàtọ̀ sí pé ki ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó yàtọ̀ sí àkọsílẹ̀ òfin wáyé gbogbo ọmọ-ẹgbẹ́ pátá ni ó gbọdọ̀ pẹ́jú wámú si ìpàdé Ilé-Ẹjọ́ náà.

2. Àdéhùn yìí wà l'ọ́wọ́ pe àwọn adájọ́ àgbà tí ó pẹ́jú si ìpàdé náà kò di ní mọ́kànlá. Òfin Ilé-Ẹjọ́ náà lè fààyè kí adájọ́ àgbà kan tàbí jù bẹ́ẹ̀, gẹ́gẹ́ bí nǹkan bá ṣe ri ní ìpàdé náà dá ẹjọ́ náà.
3. Ìpàdé Ilé-Ẹjọ́ náà lè bẹ̀rẹ̀ bí àwọn adájọ́ àgbà bá ti pé mẹ́sàn-án.

## *Kókó-àdéhùn 26*

1. Bí Ilé-Ẹjọ́ náà bá fẹ́; ó lè yan ìgbìmọ̀ adájọ́ kan tàbí jù bẹ́ẹ̀, ti yóò jẹ́ pe adájọ́ àgbà mẹ́ta ni yóò jẹ́ ọmọ ìgbìmọ̀ bẹ́ẹ̀. Ìgbìmọ̀ bẹ́ẹ̀ yóò máa yanjú oríṣiríṣi ẹjọ́. Bí àpẹẹrẹ; ọ̀rọ̀ tó jẹ́ ẹgbẹ́ àwọn òṣìṣẹ́ àti ìgbòkègbodò ètò ìrìnnà lọ́gún.

2. Nígbà kíígbà ní Ilé-Ẹjọ́ náà lè yan ìgbìmọ̀ adájọ́ ti yóò máa yanjú ẹjọ́ tí ó ba wà nílẹ̀. Ilé-Ẹjọ́. náà ni yóò l'ágbára láti yan iye adájọ́ àgbà ti yóò wà nínú àjọ náà lẹ́yìn tí tọ̀tún-tòsì bá ti f'ọwọ́síi.

3. Àjọ náà lẹ́tọ̀ọ́ láti gbọ́ ẹjọ́ kí wọ́n sì ṣe ìpinnu tó yẹ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà nínú àdéhùn yìí bi àwọn ẹlẹ́jọ́ náà bá ti faramọ́.

## *Kókó-àdéhùn 27*

Ẹjọ́ ti èyíkéyì nínú àwọn ìgbìmọ̀ adájọ́ náà bá dá bí ó ṣe wà nínú kókó-àdéhùn 26 ati 29, Ilé-Ẹjọ́ náà ló dá a.

### *Kókó-àdéhùn 28*

Àwọn ìgbìmọ̀ adájọ́ náà lè ṣiṣẹ́ wọn ní ibòmíràn yàtọ̀ sí Ìlú Hague gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà nínú àdéhùn 26 àti 29.

### *Kókó-àdéhùn 29*

Kí iṣẹ́ ìdájọ́ Ilé-Ẹjọ́ náà lè yá; Ilé-Ẹjọ́ lè dá ìgbìmọ̀ adájọ́ ẹlẹ́ni márùn-ún, tí àwọn máràárùn yóò sì jẹ́ adájọ́-àgbà sílẹ̀. Àwọn adájọ́ àgbà náà lè tètè gbọ́ ẹjọ́ náà bí àwọn ẹlẹ́jọ́ bá fẹ́ ẹ bẹ́ẹ̀. Ní àfikún, wọn ó yan adájọ́ àgbà méjì láti rọ́pò àwọn adájọ́ àgbà tí kò bá lè wá sí ìpàdé ìgbìmọ̀-adájọ́ náà.

### *Kókó-àdéhùn 30*

1. Ilé-Ẹjọ́ náà yóò ṣe òfin ti yóò máa lo láti tọ́ ọ ṣọ́nà nínú iṣẹ́ rẹ̀. Pàtàkì jùlọ, yóò ṣe òfin tí yóò máa ṣe amọ̀nà ìgbésẹ̀ rẹ̀.

2. Ànfàní yóò wà f'áwọn aláyẹ̀wò láti yẹ òfin Ilé-Ẹjọ́ náà wò tàbí pẹ̀lú èyíkéyìí nínú àwọn ìgbìmọ́ ìdájọ́ rẹ̀ láì lẹ́tọ̀ọ́ sí ìbò dídì.

### *Kókó-àdéhùn 31*

1. Àwọn adájọ́-àgbà tí ó wá láti orílẹ̀-èdè àwọn ti èdèàìyedè wà láàrín wọn lẹ́tọ̀ọ́ láti pẹ̀lú àwọn adájọ́ àgbà tó kù láti gbọ́ ẹjọ́ tí Ilé-Ẹjọ́ náà ń dá.

2. Bí Ilé-Ẹjọ náà bá yan adájọ́-àgbà kan tí ó wá láti orílè-èdè ọ̀kan lára àwọn ti aáwọ̀ wà láàrín wọn kí ó wá dá sí ọ̀rọ̀ aáwọ̀ náà; enikẹ́ni ló lè yan adájó-àgbà mììrán láti dá ẹjọ́ náà. Lára àwọn tí wọ́n yàn gẹ́gẹ́ bíi kókó-àdéhùn 4 àti 5 wọn ó ti yan irú àdájọ́-àgbà bẹ́ẹ̀.

3. Bí Ilé-Ẹjọ́ náà ò bá fi adájọ́-àgbà tí ó wá láti orílẹ̀-èdè àwọn tí ìjà wà láàrín wọn.si i,ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn oníjà náà ló lè yan adájọ̀-àgbà gẹ́gẹ́ bíi ìlànà tí ó wà ni Ìpínfọ̀ 2 nínú àdéhùn yí.

4. Ìgbékalẹ̀ kókó-àdéhùn yí náà la ó lò fún kókó-àdéhùn 26 àti 29. Bí irú èyí bá ṣẹlẹ̀, Ààrẹ yóò bẹ ẹnìkan tàbí méjì nínú ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-Ẹjọ́ náà tí wọ́n jẹ́ ọmọ oríl̀ẹ-èdè tí ó ń jà náà. Bí èyí bá yẹ̀ tàbí wọn kò lè ráyè wá, kí àwọn tó ń jà náà yan àwọn àgbà amòfin láti bá wọ́n dá sí i.

5. Bi ọwọ́ tí ó níl̀ẹ́ẹ́ si nǹkankan náà, ẹgbẹ́ kan ṣoṣo ni wọ́n ó kà wọ́n kún fún àǹfàní àwọn ohun tí wọ́n ti pèsè tẹ́lẹ̀. Bi kókó yìí bá rújú, Ilé-Ẹjọ́ náà ni yóò ṣe àtúnṣe ọ̀rọ̀ náà.

6. Àwọn adájọ́-àgbà tí wọn ti mẹ́nubà ni ìpínfọ̀ 2, 3 àti 4 tinú kókó-àdéhùn 2, 17 (Ìpìpínfọ̀ 2) 20, àti 24 bí ó ṣe wà nínú àgbékalẹ̀ òfin yii. Àwọn pàá máa kópa ninú ìpinnu náà.

## *Kókó-àdéhùn 32*

1. Gbogbo àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-Ẹjọ́ náà ni wọn yóò máa gbowó-oṣù lọ́dọ́ọdún.

2. Ààrẹ yóò máa gbowó kan láàyè ọ̀tọ̀ lọ́dọ́ọdùn yàtọ̀ sí owó oṣù

3. Gbogbo ọjọ́ tí igbákejì Ààrẹ bá ti delé de Ààrẹ ni yóò máa gbowó kan láàyè ọ̀tọ̀.

4. Gbogbo ọjọ́ tí àwọn adájọ́-àgbà tí wọ́n yàn lábẹ́ kókó-àdéhùn tí wọ́n yàn lábẹ́ kókó-àdéhùn 31, yàtọ̀ sí àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Ilé-Ẹjọ́ náà bá ti ṣojúṣe wọn ni wọn yóò máa gbowó-iṣẹ́ láti fi dùn wọ́n nínú.

5. Ìpàdé Gbogboògbò ni yóò sọ iye tí owó-oṣù, àti àwọn owó-iṣẹ́ mìíràn yàtọ̀ sí owó-oṣù yóò máa jẹ. Àlékún lè má sìí lórí àwọn owó yìí bí àwọn òṣìṣẹ́ wọ̀nyen bá fi wà lẹ́nu iṣẹ́.

6. Ìpàdé Gbogboògbò ni yóò f'ẹnukò lórí owó-oṣù Rẹ́gísírà lórí àbá ti Ilé-Ẹjọ́ náà bá dá lórí owó-oṣú Rẹ́gísírà.

7. Òfin ti Ìpàdé Gbogboògbò bá şe ni yóò pinnu bí wọn ò ş
máa sanwó ìfèyìntí fún àwọn òşìşé Ilé-Ẹjọ́ náà àti Régísí
pèlú. Bákan náà, ọ̀nà ti àwọn òşìşé Ilé-Ẹjọ́ náà àti Régísí
yóò máa fi gba òwó tí wọ́n bá ná ní ìrìnjò padà.

8. Wọn kò ni máa yọ owó-orí nínú àwọn owó wọ̀nyí.

## *Kókó-àdéhùn 33*

Àjọ àpapọ̀ orílè-èdè ni yóò máa gbé ìnáwó Ilé-Ẹjọ́ náà :
ọ̀nà ti Ìpàdé àpapọ̀ bá f'ẹnukò sí.

# Orí Kejì

## *Dídáńgáńjíá Ilé-Ẹjọ́ náà*

### *Kókó-àdéhùn 34*

1. Àwọn orílẹ̀-èdè nìkan ni wọ́n lè gbẹ́jọ́ wá síwájú Ilé-Ẹjọ́ náà.

2. Ni ìbámu pẹ̀lú òfin Ilé-Ẹjọ́ náà, ó lè.bẹ àwọn àjọ àgbáyé kí wọ́n là wọ́n lóye lórí ẹjọ́ ti wọ́n bá gbé wá síwájú wọn. Wọn yóò si gba ohun tí àjọ náà bá sọ fún wọn yẹ̀wò fínnífínní bó ṣe yẹ lérò tiwọn.

3. Ìgbákígbà tí Ilé-Ẹjọ́ náà bá ti gba ìmọ̀ràn tàbí ìlanilóyẹ̀ lọ́dọ̀ àwọn ẹgbẹ́ àgbáyé tí a sọ yìí, iṣẹ́ Rẹ́gísírà ni láti fi tó àwọn àjọ bẹ́ẹ̀ létí ki wọ́n si fi ẹ̀dà àbájáde Ilé-Ẹjọ́ náà tó wọn lẹ́tí.

### *Kókó-àdéhùn 35*

1. Ilé-Ẹjọ́ náà yoò máa tórí àwọn orílẹ̀-èdè tí ó lọ́rọ̀ ṣiṣẹ́ ní ìbámu pẹ̀lú àkọsílẹ̀ òfin yìí.

2. Kí Ilé-Ẹjọ́ tó ṣàdéédé bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ torí àwọn orílẹ̀-èdè yòókù, ó gbọdọ̀ wà ní ìbámu pẹ̀lú àkọsílẹ̀ ẹgbẹ́ ti wọ́n ń lò lọ́wọ́, kí ó sì jẹ́ èyí tí Àjọ alábòójútó gbé kalẹ̀. Àmọ́ àwọn igbésẹ̀ wọ̀nyí ò gbọdọ̀ dun orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ lẹ́tọ̀ọ́ wọn níwájú Ilé-Ẹjọ́ náà.

3. Ilé- Ẹjọ́ náà ni yóò sọ iye owó ti orílẹ̀-èdè ti kì í ṣe ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè ti ó ní ẹjọ́ níwájú Ilé-Ẹjọ́ náà yóò san láti fi kún owó Ilé-Ẹjọ̀ náa. Bi ó bá jẹ́ pé orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ ló bá gbé nínú owó ti Ilé-Ẹjọ́ náà yóò lò kalẹ̀ kò ni san èyí tí a wí yẹn mọ́.

1. Ilé-Ẹjọ́ náà lágbára láti gbọ́ gbogbo ẹjọ́ tí wọn bá gbé wá bá a àti gbogbo ọ̀rọ̀ tí ó jẹyọ nínú àdéhùn Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè tàbí àkọsílẹ̀ ẹgbẹ́ àti àṣà àjọ náà.

2. Nígbàkígbà ni àwọn orílẹ̀-èdè tí ó lẹjọ́ níwájú Ilé-Ẹjọ́ náà lè sọ pé àwọn o f'aramọ́ àkọsílẹ̀ òfin yìí. Bẹ́ẹ̀ ni orílẹ̀-èdè míìràn pàápàá lâì jẹ́ pé ìpinnu kan danin wa lé taramọ́ ìgbésẹ̀ náà. Agbára Ilé-Ẹjọ́ náà lórí ọ̀rọ̀ ìjà ajemofin nípa:

   a. Àlàyé lórí Àkọsílẹ̀ ẹgbẹ́
   b. Gbogbo ọ̀rọ̀ tó jẹ mófin àgbáyé
   d. Ọ̀rọ̀ tí ó lè ba àjọṣe àgbáyé jẹ́.
   e. Bí wọn ó ṣe sanwó (ìyànjẹ) fúnbíba àjọṣe àgbáyé jẹ́.

3. Àwọn nǹkan tí wọ́n sọ yìí ò gbọdọ̀ pọn dandan fún orílẹ̀-èdè kan, tàbí kí ó jẹ́ àjùmọ̀gbà àwọn orílẹ̀-èdè ti ọ̀rọ̀ náà bá kàn fún ìgbà kan.

4. Ọ̀dọ̀ Akọ̀wé-Gbogboògbò Àjọ àpapọ̀ orílè-èdè ni wọn ó gbè é àwọn àgbékalẹ̀ wọ̀nyí sí, ki òun pàá tó wá fi ẹ̀dà ṣọwọ́ si àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ to kópa nínú ètò àkọsílẹ̀ òfin àti si Rẹ́gísírà Ilé-Ẹjọ́ náà pẹ̀lu.

5. A ó gba àwọn ìgbéjáde tí ó wà lábẹ kókó-àdéhùn 36 tinú àkọ́sílẹ̀ òfin Ilé-Ẹjọ́ idájọ́ òdodo ayérayé tí wọ́n sì ń lò báyìí gẹ́gẹ́ àjọmọ̀ àwọn tí ọ̀rọ̀ wọn wà níwájú Ilé-Ẹjọ́ àti àkọ́sílẹ̀ òfin yìí. Kí ó lè jẹ ohun àtẹ́wọ́gbà, Ilé Ẹjọ́ idájọ́ òdodo àgbáyé ò gbọdọ̀ máa ṣàátó gẹ́gẹ́ bíi òfin àti àdéhùn Ilé-Ẹjọ́ náà.

6. Bí ó bá ṣ̣ẹlẹ̀ pé èdèàìyedè wáyé nípa pé Ilẹ́-Ejọ́ náà ò láṣẹ tàbí agbára lórí ọ̀rọ̀ kan, ìpinnu Ilé-Ẹjọ́ náà ni wọn yóò lò láti yanjú èdèàìyedè náà.

## *Kókó-àdéhùn 37*

Bóyá òfin tàbí ìpinnu ìpàdé ni wọn ń lo láti fi ṣe àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀ kan láti dá Àgbájọ orílẹ̀-èdè sílẹ̀ tàbi Ilé-Ẹjọ́ ìdájọ́ òdodo ayéraye tí kò sì lójútùú, ọ̀dọ̀ Ilé-Ẹjọ̀ ìdájọ́ òdodo ni wọn yóò darí ẹjọ́ bẹ́ẹ̀ sí.

## *Kókó-àdéhùn 38*

1. Ìwọ̀nyí ni ìgbésẹ̀ tí Ilé-Ẹjọ́ náà, èyí tí ojúṣe rẹ̀ ni láti pinnu ni ìbámu pẹ̀lu òfin àgbáyé lórí aáwọ̀ gẹ́gẹ́ bí wọ́n bá ṣe gbé e kalẹ̀ síwájú ẹ̀:

   a. Àgbájọ ìpàdé àgbàyé yálà èyí tí wọ́n dá ṣe tàbí ti gbogboògbò ti yóò ṣòfin lọ́nà tí ó yá kankan tí àwọn orílẹ̀-èdè tí aáwọ̀ wà láàrín wọn yóò si gbà wọlé.

   b. Ìṣe kárí ayé tí ó jẹ́ ìtẹ́wọ̀ gba òfin

   d. Ìgbékalẹ̀ òfin lọ́nà tí ó fi jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà àwọn orílẹ̀-èdè tí ó ti wà níwájú àwọn orílẹ̀-èdè yòókù ní tọ̀làjú.

   e. Bí ìlànà ọhun tí kókó-àdéhùn 59 sọ, ìpinnu òfin àti kíkó olóye ẹ̀dá nípa ètò àwùjọ àwọn orílẹ̀-èdè lóríṣìríṣi gẹ́gẹ́ bíi àṣekún láti ri pé ẹsẹ̀ òfin múlẹ̀ gbọdọ̀ fẹsẹ̀ rinlẹ̀ daada.

2. Ìpèsè wònyí ò gbọdọ̀ f'ojú tẹ́mbẹ́lú agbára Ilé-Ẹjọ́ náà nínú ìpinnu rẹ̀ láti parí aáwọ̀ bi àwọn oníjà náà bá ti faramọ́ pé kí wọn parí èdèàìyedè àárín àwọn.

# Orí Kẹta

## Ìgbésè

### Kókó-àdéhùn 39

1. Èdè Faransé àti Gẹ̀ẹ́sí ni èdè ti Ilé-Ẹjọ́ náà yóò máa lò. Bí àwọn oníjà bá ni èdè Faransé làwọn yóò rojọ́, èdè Faransé náà ni kí wọ́n fi dájọ́ náà. Bí wọ́n bà sì ní èdè Gẹ̀ẹ́sì l'àwọn fẹ́ fi rojọ́, ẹ̀dẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì ni kí wọn fi dájọ́ náà.

2. Bí ó bá ṣẹlẹ̀ pe kò sí pé àfi èdè kan nínú méjéèjì; oníjà kọ̀ọ̀kan lè lo èdè tí ó bá wu un rojọ́ ẹ, àmọ́ èdè Faransé àti Gẹ̀ẹ́sì ni Ilé-Ẹjọ́ yóò fi gbé ìpinnu rẹ̀ kalẹ̀. Bi ọ̀rọ̀ bá ri bàyìí. Ilé-Ẹjọ́ ni yóò mọ èdè tí ó tọ́ láti fi dájọ́ nínú méjéèjì náà.

3. Bí l'ára àwọn ti èdèàìyedè wà láàrín wọn bá tọrọ ààyè lọ́wọ́ Ile-Ẹjọ́ náà pe kí wọ́n jẹ́ kí òun lo èdè mìíràn yàtọ̀ sí yálà Faransé tàbí Gẹ̀ẹ́sì Ilé-Ẹjọ́ gbọdọ̀ gbà á láàyè kí ó lo èdè bẹ́è.

### Kókó-àdéhùn 40

1. Oríṣiríṣi ọ̀nà ni wọ́n fi lè gbẹ́jọ́ wá síwájú Ilé-Ẹjọ́ náà gégé bí ẹjọ́ náà bá se jẹ́. Ó lè jẹ́ nípa fífi ìpinnu pàtàkí tó Ilé-Ẹjọ́ náà létí; tàbí nípa kíkọ ìwé ṣọwọ́ si Rẹ́gísírà. Èyí tó wù kó jẹ́ kókó ẹjọ́ àti àwọn tí ó ń jà náà gbọdọ̀ wà níbẹ̀ kedere.

2. Léyìn ìgbà náà ni Rẹ́gísírà yóò wá fi ìwé náà ṣọwọ́ sí àwọn tọ́rọ̀ náà kàn.

3. Ó gbọdọ̀ fi tó àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè létí nipa sísọ fún Akọ̀wé-Gbogboògbò, ẹni tí yóò tàn án kárí àwọn ọmọ-ẹgbẹ́.

### *Kókó-àdéhùn 41*

1. Ilé-Ẹjọ́ náà yóò ní agbára láti sọ bí ààbò àti ẹ̀tọ́ àwùjọ ẹ̀dá bá tọ́ si àwọn orílẹ̀-èdè náà.
2. Kí wọ́n tó fẹnu ìpinnu wọn jóná, wọn kọ́kọ́ gbọdọ̀ fi ìgbésẹ̀ tí wọ́n gbé lórí ọ̀rọ̀ náà tó àwọn tó ń jà náà àti Àjọ Alábò-ójútó létí.

### *Kóko-àdéhùn 42*

1. Àwọn orílẹ̀-èdè tó ń jà náà gbọdọ̀ ní aṣojú.
2. Wọ́n tiẹ̀ lè gba agbẹjọ́rò tí yóò wa ṣ'ojú ẹ̀ nílé ẹjọ́
3. Ààbò tó yẹ yóò wà fún ẹlẹ́jọ́, amòfin àti àwọn aṣojú ẹlẹ́jọ́ tó gbà wọ́n láti ṣe iṣẹ́ wọn.

### *Kókó-àdéhùn 43*

1. Ọ̀nà méjì ni ìjábọ̀ ètò ìpàdé náà yóò jẹ́: kíkọ́ sílẹ̀ àti sísọ lẹ́nu.
2. A ó fi ètò ìjábọ̀ tí a kọ sílẹ̀ ṣọwọ́ sí Ilé-Ẹjọ́ náà àti sí àwọn ọlọ́rọ̀, àti àwọn alátakò, bí ó bá ṣe é ṣe, a ó fi èsì àti gbogbo ìwé àti ṣègbè ìjabọ̀ náà ṣọwọ́.
3. Rẹ́gísírà Ilé-Ẹjọ́ náà la ó fi àwọn àbọ̀ ìpàdé náà ṣọwọ́ sí létòlétò láàrín àkókò tí Ilé-Ẹjọ́ náà fẹnukò sí.
4. Ẹ̀dà gbogbo ìwé tí a ti wò fínnífínní tí ọ̀wọ́ kan fi gbé ọ̀rọ̀ rẹ̀ lẹ́sẹ̀ la gbọdọ̀ fi ṣọwọ́ si ọ̀wọ́ kejì
5. Gbogbo ohun ti Ilé-Ẹjọ́ náà gbọ́ lẹ́nu àwọn ẹlẹ́rìí, onímọ̀, aṣojú, agbẹjọ́rò àti amòfin ni ó gbọdọ̀ hàn nínú ìjabọ̀ tí wọ́n sọ lẹ́nu.

### *Kókó-àdéhùn 44*

1. Bí Ilé-Ẹjọ́ náà bá fẹ́ fi ìwé ìpe-àkíyèsí ṣọwọ́ si àwọn ti wọn kì í ṣe aṣojú, agbẹjọ́rò àti amòfin, ìjọba orílẹ̀-èdè tí ìwé náà ń lọ ni wọn ó fi ìwé ọ̀hún ṣọwọ́ sí.

2. Ètò yí kan náà ni wọ́n gbọdọ̀ tẹlé bí wọ́n bá gbé ìgbésẹ̀ láti wá àrídájú l'ójú-ẹsẹ̀.

### *Kókó-àdéhùn 45*

Lábẹ́ àṣẹ Ààrẹ ni wọ́n ó ti gbọ́ ẹjọ́ náà tàbí bí Ààrẹ bá lè jẹ́ alága ẹjọ́ náà, Igbákejì rẹ̀ yóò gbọ́ ọ. Bí èyíkèyìí ò bá láǹfàní láti gbọ́ ẹjọ́ náà àgbà nínú amòfin yóò darí ètò ìgbẹ́jọ́ náà.

### *Kókó-àdéhùn 46*

Ìta gbangba lójú àwọn èrò ni Ilé-Ẹjọ́ náà gbọdọ̀ gbọ́ ẹjọ́ àyàfi bí Ilé-Ẹjọ́ bá ní bẹ́ẹ̀ kọ́ tàbí bí àwọn ẹlẹ́jọ́ bá ní àwọn ò fẹ́ ki aráàlú wọlé ẹjọ́.

### *Kókó-àdéhùn 47*

1. Ohun gbogbo tí wọ́n bá sọ ní ìpàdé kọ̀ọ̀kan ni Régísírà gbọdọ̀ kọ sílẹ̀, kí ó sì f'ọwọ́ sí i.

2. Ìjabọ̀ ìpàdé tí a kọ sílè náà yóò jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà àwọn èèyàn.

### *Kókó-àdéhùn 48*

Ilé-Ẹjọ́ ni yóò pàṣẹ l'órí bí wọn ó ṣe ṣẹjọ́ náà. Òun náà ni yóò fẹnukò lórí bí ẹjọ́ náà yóò ṣe rí àti àkókò tí ẹlẹ́jọ́ kọ̀ọ̀kan yóò fi parí ọ̀rọ̀ tiẹ̀. Ilé-Ẹjọ́ náà ni yóò ṣètò nípa kíkọ́-ọ̀rọ̀ ẹlẹ́rìí sílẹ̀.

### *Kókó-àdéhùn 49*

Ki àsìkò ìgbẹ́jọ́ tó tó, Ilé-Ẹjọ́ náà lé pe àwọn aṣojú kí wọn fiwé ránṣẹ́ tàbí kí wọ́n fi àlàyé ọ̀rọ̀ mú un dá wọn lójú. Kí a ṣe àkíyèsí, kí a sì kọ ọ́ sílẹ̀ bí òrílẹ̀-èdè kan bá kọ̀.

### Kókó-àdéhùn 50

Ilé-Ẹjọ́ náà lè yan ẹnìkan, àjọ kan tàbí àwọn ẹgbẹ́ alátúnúnṣe kan, kí wọ́n lọ gba onímọ̀-ìjìnlẹ̀ kan láti wá sọ ohun tó rò nípa ọ̀rọ̀ náà.

### Kókó-àdéhùn 51

Bí Ilé-Ẹjọ́ bá ń gbọ́ ẹjọ́ lọ́wọ́, ẹlẹ́rìí àti onímọ̀ la ó máa d'ojú àwọn ìbéèrè tó bá ẹjọ́ tí wọ́n ń rò mu kọ, gẹ́gẹ́ bí òfin Ilé-Ẹjọ́ náà, bí o ṣe wà nínú kókó-àdéhùn 30.

### Kókó-àdéhùn 52

Lẹ́yìn tí Ilé-Ẹjọ́ náà bá ti rí kókó ìdánilójú àti ẹ̀rí'dìmú láàrín àkókò tó yẹ fún ẹjọ́ náà, ó lè l'òun ò fẹ́ yálà ẹ̀rí tí wọ́n fi ẹnu jẹ́ tàbí tí wọ́n kọ sílẹ̀ ti èyíkèyìí nínú àwọn ẹlẹ́jọ́ náà bá fẹ́, àyàfi bí ọ̀kan lára wọn bá faramọ́ ọn.

### Kókó-àdéhùn 53

1. Bí èyíkéyìí nínú àwọn oníjà náa bá kọ̀ láti yọjú sílé ẹjọ́ tàbí kọ̀ láti wá ro tẹnu ẹ̀, ẹni kejì lè sọ fún Ilé-Ẹjọ́ pé kí wọ́n dá òun láre.

2. Ilé-Ẹjọ́ gbọdọ̀ tẹ ara rẹ̀ lọ́rùn látàrí èyí kí ó tó dá ẹjọ́ náà bẹ́ẹ̀. Kì í ṣe pé ó laṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí ohun tó wà nínú àwọn kókó-àdéhùn 36 àti 37, nìkan; òfin pàá gbà á láàyè láti ṣe bẹ́ẹ̀.

### Kókó-àdéhùn 54

1. Ìgbàkúgbà ti Ilé-Ẹjọ́ bá lágbára lórí ìgbékalẹ̀-ẹjọ́ tí àwọn aṣojú, agbẹjọ́rò àti amòfin bá ṣe, Ààrẹ ni yóò fi òpin sí gbígbọ́ ìgbákalẹ̀-ẹjọ́ náà.

2. Ilé-Ẹjọ́ náà yóò fi sùúrù gbé ìdájọ náà yẹ̀wò.

3. Ìkọ̀kọ̀ ni Ilé-Ẹjọ́ náà yóò pàdé, àbájáde wọn kò sì gbọdọ̀ lu jáde.

## *Kókó-àdéhùn 55*

1 Ohun ti ọ̀pọ̀ àwọn adájọ́ tó bá wá sílé-ẹjọ́ bá sọ l'abẹ́ yóò gé.

2. Bí abájáde èsì ìbò bá jẹ́ ọgbọọgba, yálà Ààrẹ tàbí adájọ́ àgbà tí ó bá ń delé dè é yóò dìbò kan láti fi yanjú òmìn náà.

## *Kókó-àdéhùn 56*

1. Wọn gbọdọ̀ sọ ìdí ti wọ́n fi dájọ́ bí wọ́n bá ṣe dá a.

2. Orúkọ àwọn amòfin àgbà tí wọ́n kópa nínú ìdájọ́ ọ̀hún gbọdọ̀ wà nínú ìwé ìdájọ́ náà.

## *Kókó-àdéhùn 57*

Bí ẹnu àwọn adájọ́-àgbà náà ò bá kò lórí ètò ìdájọ́ ọ̀hun, adájọ́-àgbà tí kò bá fi ara mo bi won se dajo naa lẹtọọ lati fi èrò tiẹ̀ hàn láàyè ọ̀tọ̀.

## *Kókó-àdéhùn 58*

Ààre àti Rẹ́gírísà gbọdọ̀ f'ọwọ́ sí ìwé ìdájọ́ náà. Lẹ́yìn tí wọ́n bá ti fi tó àwọn aṣojú àwọn tọ́rọ̀ náà kàn létí, wọn yóò ka ìdájọ́ náà lójú gbogbo wọn nílé-ẹjọ́

## *Kókó-àdéhùn 59*

Kò pọn dandan kí àwọn oníjà náà faramọ́ ìdájọ́ Ilé-Ẹjọ́ náà àyàfi bí àwọn ẹlẹ́jọ́ náà bá faramọ́ ọn àti pẹ̀lú ó lè jẹ pé irú ẹjọ́ bẹ́ẹ̀ nìkan ni wọ́n lè faramọ́.

## *Kókó-àdéhùn 60*

Ibi tí wọ́n bá ti dájọ́ sí labẹ gé, kò sí pé ẹnìkan ń pejọ́ kò tẹ̀ mi lọ́rùn. Bí ó bá wá ṣẹlẹ̀ pe ìtumọ̀ ẹjọ́ náà ò yé ẹnìkan nínú àwọn oníjà náà. Ilé-Ẹjọ́ náà gbọdọ̀ ṣàlàyé fún un.

## *Kókó-àdéhùn 61*

1. Ìgbà tí wọ́n bá ṣe àkíyèsí pé àìṣedéédé wà nínú ìdájọ́ náà nípa pé àwọn kókó tó yẹ kó wà nínú ọ̀rọ̀ náà ò sí kí wọ́n tó dájọ́, wọ́n lè tun ẹjọ́ náà rò, kí wọ́n tún un dá. Èyí lè wáyé bi ìdánilójú bá wà pé àìmọ̀ Ilé-Ẹjọ́ tàbí ọ̀kan lára àwọn ẹlẹ́jọ́ ló fà á tí kì í ṣe pé wọ́n mọ̀ọ́mọ̀ f'ojú fo kókó náà.
2. Nípa ẹ̀rí tuntun ti ó wà níwájú Ilé-Ẹjọ́ náà ni ètò ìtúndá-ẹjọ́ náà yóò gùn lẹ́. Ilé-Ẹjọ́ náà yóò gbé ẹjọ́ náà f'áyé gbọ́ kí ó sì sọ pé Ilé-Ẹjọ́ náà gba láti ṣe àtúndà ẹjọ́ náà.
3. Ilé-Ẹjọ́ náà lè ní kí wọ́n jẹ́ kí òun ri ìgbésẹ̀ ètò ìdájọ́ tí wọ́n ti fẹnukò lé lórí tẹ́lẹ̀, kí òun tó tún ẹjọ́ náà dá.
4. Láàrín oṣù mẹ́fà ti ẹ̀rí-òdodo ọ̀tun bá ti fojú hàn ni ìpè fun àtúndá-ẹjọ́ náà gbodọ̀ ti jáde.
5. Kò ni si ìpè fún àtúndá ẹjọ́ kankan mọ́ lẹ́yìn ọdún mẹ́wàá tí wọ́n bá ti dájọ́ náà.

## *Kókó-àdéhùn 62*

1. Bi orílẹ̀-èdè kan bá rò pe òun nífẹ̀ẹ́ sí bí wọn ṣe ń dájọ́ kan, èyí tí ó lè kópa lórí ẹjọ́ náà, ó lè tọrọ ààyè lọ́wọ́ Ilé-Ẹjọ́ náà ki ó jẹ́ ki òun náà dá sí i.
2. Ilé-Ẹjọ́ náà ló lè pinnu bóyá ki òun gba orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ lááyè láti dá sí ẹjọ́ náà.

## *Kókó-àdéhùn 63*

1. Ìgbàkúgbà ti ìpàdé ti yóò kó àwọn orílè-èdè yàtọ̀ si àwọn tí ó ń jà bá máa wáyé, Rẹ́gísírà gbọdọ̀ fi tó wọn létí lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀.
2. Gbogbo orílẹ̀-èdè tí wọ́n bá tí fi ìpàdé náà tó létí ló láṣẹ láti dá si ọ̀rọ̀ náà. Bí ó ti laṣẹ àti dá sí ẹjọ́ náà ni ó gbọ́dò faramọ́ ẹjọ́ tí wọ́n bá dà náà.

## *Kókó-àdéhùn 64*

Àyàfi bí Ilé-Ẹjọ́ bá pinnu lááyè ọ̀tọ̀, kálukú àwọn orílẹ̀-èdè tí ó ń jà ni yóò náwó àpò ara rẹ̀.

# Orí Kẹrin

## Èrò Olùdámọ̀ràn

### Kókó-àdéhùn 65

1. Ilé-Ẹjọ́ náà lè fi èrò tiẹ̀ hàn lórí ọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ ọ̀rọ̀ ofin ki ó si gbà wọ́n ni ìmọ̀ràn bí àjọ tí ó láṣẹ kan bá fẹ bẹ́ẹ̀ tàbí ti ó bá wà ni ìbámu pẹ̀lú àdéhùn àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè tí ó ni èèyàn lè béèrè fún èrò àti ìmọ̀ràn bẹ́ẹ̀.

2. Ọ̀rọ̀ tí wọ́n ní kí Ilé-Ẹjọ́ náà dá sí gbọdọ̀ wà ní àkọsílẹ̀, ki wọ́n si kọ́kọ́ gbé e síwájú Ilé-Ẹjọ́ náà, kí wọ́n sì sọ ni pàtó ọ̀rọ̀ ti wọ́n fẹ́ ki Ilé-Ẹjọ́ náà dá sí. Wọ́n sì gbọdọ̀ fi àwọn ìwé tí yóò tan ìmọ́lẹ̀ si ọ̀rọ̀ náà daada fun Ilé-Ẹjọ́ náà ṣọwọ́ pẹ̀lú ẹ̀.

### Kókó-àdéhùn 66

1. Kíá ni Régísírà yóò ti fìwé ṣọwọ́ sí àwọn orílẹ̀-èdè tí ó tọ́ kí wọ́n yọjú sílé-ẹjọ́ náà láti wá fi èrò wọn hàn. Kí wọ́n sì gba àwọn tó fẹ́ ìmọ̀ràn náà ni ìmọ̀ràn.

2. Régísírà tún gbọdọ̀ mọ ọ̀nà tí yóò gbé e gbà tí yóò ṣe fi tó orílẹ-èdè tó yẹ kí ó farahàn nílé-ẹjọ́ náà tàbí àjọ àgbáyé tí Ilé-Ẹjọ́ náà rò pé ó lè ṣé e. Bi kò bá ní sí ìjókòó ìdájọ́ ti Àarẹ má ń pè tí ó ti má ń fi ìṣẹ̀lẹ̀ tó ọmọ-ẹgbẹ́ létí, ó gbọdọ̀ ti fi tó wọn léti láàrín àsìkò tó yẹ lójú rẹ̀. Ó lè jẹ pé n ṣe lo máa kọ ọ́ tàbí sọ ọ́ sétíìgbọ́ wọn ni ìpàdé gbamgba tí ó bá wáyé fún ìdí náà. Ó lè jẹ́ ọ̀rọ̀ ẹnu tí ó jẹ mọ ọ̀rọ̀ náà.

3. Bi orílẹ̀-èdè tí ó yẹ kí ó fojú ba Ilé-Ẹjọ́ náà ò ba tètè ríwèé ìpè tí ó wà ni ìpínfọ̀ kejì kókó-àdéhùn yí, orílẹ̀-èdè bẹ́ẹ̀ lè ní kí wọ́n jẹ ki òun fi ìwé lélẹ̀, tàbí ki won gbọ́ tòun léyìn náà Ilé-Ẹjọ́ yóò pinnu lóri ọ̀rọ̀ náà.

4. Àayè yóò wà fún orílẹ̀-èdè àti àjọ tí wọ́n ti kọwé tàbi fohùn sílẹ̀ tàbí tó ṣe méjèèjì láti sọ̀rọ̀ lórí ọ̀rọ̀ tí orílẹ̀-èdè tàbí àjọ

ti sọ ní ìpàdé Ilé-Ẹjọ́ náà ti Ààrẹ yóò f'àṣẹ sí i. Bẹ́ẹ̀ náà ni Rẹ́gísírà náà yóò tètè fiwé tó jẹ mọ ọ̀rọ̀ náà s'ọwọ́ si orílẹ̀-èdè àti àjọ ti wọn ti kọ irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀.

## *Kókó-àdéhùn 67*

Ìta gbangba ni Ilé-Ẹjọ́ náà yóò ti fi èrò àti ìmọ̀ràn rẹ̀ hàn, wọn ó tí mú un wá sétíìgbọ́ Akọ̀wé– gbogboògbò àti aṣojú àwọn ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè pẹ̀lú àwọn orílẹ̀-èdè mìíràn. àti àwọn àjọ àgbáyé ti ọ̀rọ̀ náà kàn gan.

## *Kókó-àdéhùn 68*

Nínú ojúṣe Ilé-Ẹjọ́ náà bíi olùdámọ̀ràn, àkọsílẹ̀ òfin yìí ni yóò máa tọ́ ọ sọ́nà bí ẹjọ́ bá jẹ́ èyí ti ó ṣẹ̀ si Ilé-Ẹjọ́.

# Orí Karùn-ún

## *Àtúnṣe*

### *Kókó-àdéhùn 69*

Ìgbésẹ̀ ti àdéhùn Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè gbé fún àtúnṣe àdéhùn yẹn ni àkọsílẹ̀ òfin yìí yóò tẹ̀lé. Ìyípadà lè bá ìgbésẹ̀ náà bí Àjọ Alábòójútó bá dá àbá tó yàtọ̀ fún Ìpàdé Gbogboògbò tí wọ́n sì gbà á wọlé, bí ó bá jẹ mọ̀ ìkópa àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n wà lára àwọn tó ṣòfin yìí àmọ́ tí wọ́n kì í ṣe ọmọ-ẹgbẹ́ Àjọ àpapọ̀ orílẹ̀-èdè.

### *Kókó-àdéhùn 70*

Ilé-Ẹjọ́ náà yóò lágbára láti dábàá irú àtúnṣe bẹ́ẹ̀ si àkọsílẹ̀-òfin yìí, bí ó bá rò pé ó tọ́nà. Yóò ṣe èyí nípa kíkọ̀wé si Akọ̀wé-Gbogboògbò fún àgbéyẹ̀wò ni ìbámu pẹ̀lú ohun tí ó wà nínú kókó-àdéhùn 69.